# Dídúró Laarin Àlàfo

Jeffersonville, Indiana, USA
Ọjọ Kẹtalelogun, Oṣu Kẹfa, 1963

1 Mo dupẹ lọwọ rẹ, Arakunrin Neville.

Ẹ jẹ ki a wà ni idide duro fun iṣẹju kan nisisiyi, bi a ti ṣe n tẹ ori wa ba fun adura. Ẹ jẹ ki a tẹ ori wa ba, ti ebẹ-adura ti o ṣe pataki kan bawà, ṣe ẹyin yoo fi eleyi hàn nipa gbigbe ọwọ yin soke. Bayi, mu eleyi sinu ọkàn rẹ awọn ohun naa ti ẹ nilo. Ki ẹ si beere lọwọ Baba yin ọrun, pe ki o ṣe e fun yin.

2 Baba wa ọrun, a ń bọ̀ wa si ọdọ Rẹ nisisiyi ni orukọ Jesu. A ń bọ pẹlu igbagbọ pe awọn ohun ti a fẹ, a o fi hàn ninu adura. Ti a ba si gbagbọ pe a o ri ohun ti a beere fún gbà, a o ṣe e fun wa. Nisisiyi, ileri naa dáju. Ni gbogbo awọn ọdún wọnyi a ti gbeyẹwo a si mọ wipe o jẹ otitọ! A fẹ dúpẹ́ lọwọ Rẹ, ni àkọ́kọ́, nitoripe O da ẹ̀mí wa si, ti O si fi àyè gba wá pé ki a padawa si ibiyi lẹẹkansi, lapapọ. A pejọ papọ nibiyi awọn eniyan Oluwa.

A dupẹ lọwọ Rẹ fun ijọ, ati fun oluṣọ-aguntan, ati fun otitọ nla naa eyiti a kọ ijọ naa le lori nibiyi ti wọn si duro fun. A dupẹ lọwọ Rẹ fun gbogbo ẹnikọọkan ti o wà niwaju mimọ Rẹ. A si beere pe iwọ yoo ṣaanu fun wa, loni, ki O si fi oye ti a nilo, pe ki a le tun bọ jẹ́ iranṣẹ ti o jẹ pipe fun Ọ. O jẹ ifẹ ọkan wa pẹlu ki a sin ọ pẹlu íbọ̀wọ̀ ati ọkàn otitọ, pe ki Iwọ ki O le e gba eyiti o dara julọ ninu aye wa. Ni ojoojumọ, jẹ ki irin wa ki o dara to bẹẹ gẹ ti yoo jẹ wipe gbogbo ohun ti a ṣe ni ọjọ naa yoo jẹ itẹwọgba ni ọdọ Rẹ.

3 Bayi, a gbadura fun gbogbo awọn alaisan ati awọn alaini, ni oni, ti wọn wa ni iwaju mimọ Rẹ nibiyi, ati niwaju awọn ile-ijọsin Rẹ nibi gbogbo ni agbaye. Pe Jehovah nla yoo sọkalẹ pẹlu agbara Rẹ yoo si wo awọn alaisan san ati awọn ti a pọ́n lóju. Gba ogo fun orukọ nla Rẹ. Bukun fun gbogbo ohun ìkọ̀kọ̀ ti o wà ninu awọn ọkàn, ni owurọ yi, awọn ẹ̀bẹ̀ fun adura. A gbadura nisisiyi, bi O tị se bojú wolẹ si gbogbo ọkàn ti O si ri ohun ti wọn n tọka si bi wọn ti ṣe gbé ọwọ́ wọn soke, ki O si fun wọn ni awọn ifẹ́ ọkàn wọn. Ki O si bukun fún wa bi a ti ṣe ń tẹsiwaju lati sin Ọ ati nigbati a ba kuro ninu gbọngan yi ni owurọ yi ti a o si lọ si ilé wa, jẹ ki a le sọ bi awọn ti o n bọ̀ lati Emmausi. “Ṣe ọkàn wa ko gbiná ninu wa bi O ti ṣe n bawa sọrọ ni oju-ọna?” Nitori a beere in orukọ Jesu, Amin. Ẹ jẹ ki a joko.

4 Emi nifẹ lati sọ wipe o dara, ni owurọ yi, lati wa nibiyi lẹẹkansi ninu apejọpọ awọn eniyan yi, ni iwaju Oluwa. O ti pe oṣu diẹ ti emi wa si ibiyi. Ati ni ọjọ-isinmi ti o kọja emi pinu pe emi fẹ wá ṣugbọn emi rò pe ko ki ń ṣe ìfẹ́ Oluwa lọ́nàkọnà, pẹtẹlẹ ni ibiyi ko ṣe anfani ilera fún mi lọpọlọpọ. Ni kété ti emi ba de ibi pẹtẹlẹ ....atẹgun ti o wa ni ibiyi maa n ṣe lodi si ilera mi. Gbogbo ara mi yoo si maa hún mi yoo si pọ́n, emi si ro wipe kokoro ara hihún naa yoo lọ si inu ikùn mi taara. Àárẹ̀ yoo si mú mi lọpọlọpọ, otutu yoo si mú mi, ara mi yoo si maa gbọ̀n, òtútu yoo si mú mi, emi kò ni le e wá. Bi-o-tilẹ-jẹ wipe, emi dide emi si gbiyanju lati fi ipá mú ara mi lati ṣe bẹ. Ati emi.... Emi mọ̀ wipe emi.... Ibi pẹtẹlẹ yi ko dara fun ilera mi, o si jẹ́ ....emi ni ilera pipe ko si yẹ ki emi gbé níbẹ̀.

5 Bayi, a fẹ mu iroyin wá, a ni àkoko ti o dara ninu isin Oluwa, ni ita ni jakejado ibi gbogbo ni orilẹ-èdè nibiti Oluwa ti pè wa lati wàásu. Ati nisisiyi, emi ko nireti pe emi yoo waasu ni owurọ yi lori ohunkan, ṣugbọn arakunrin Neville nifẹ pe ki emi sọrọ ohunkan niwọn igbati o jẹ wipe mo wa pẹlu awọn eniyan nibiyi. O maa ń fi aye gba iru awọn ohun yi ni ọna yi, gẹgẹ bi a ti ṣe mọ Arakunrin Neville. A si nifẹ Arakunrin Neville. Ko si si ọjọ kan ti emi ko ni ronu nipa rẹ̀. (Oun, ati iyawo rẹ, ati ẹbí rẹ̀, ati awọn ọmọ rẹ̀) maa si n gbadura fun wọn. Ki Ọlọrun fi okun fun un lati le tẹ̀ siwaju si, ki o maa rin irin-ajo naa si. Gẹgẹ bi a ti ṣe mọ, àkòkò wa ti n kọja lọ. A ti sun mọ ọjọ́ ọla pẹkipẹki, eyi ni imọlẹ aṣalẹ ti ọjọ oni.

Ati emi....

6 Awọn ebi mi ti wa ni apá Iwọ oòrùn. A ni awọn akoko ti o dara. Mo ti sanra si pẹlu iwọn pọnun mejila. Mo si ti padanu mẹwa ninu rẹ lati igba ti mo ti pada de ibiyi. Billy Paulu sanra si pẹlu iwọn pọnun meji-din-logun. Rebekah, ati Sarah ati Joseph si sanra si. Iyawo mi ko sanra si ni tirẹ. Nitorinaa.... emi ko lee sọ iyẹn ni ibiyi, ṣe ẹ mọ, nitoripe emi yoo ni lati lọ si ile lẹyin igba diẹ. Nitori naa emi....ṣugbọn a ni akoko ti o dara, akoko ti o dara, a si dupẹ gidigidi.

Awa ....

7 O buru jai, mo ronú, pe n o tun pada wa, ṣugbọn ohun nla kan wà ....Ohun meji pataki ti mo padanu, ti ko si ibomiran ti o le gba ipò rẹ̀. Ohun kan, awọn ọrẹ̀ wa nibiyi, ati ijọ naa. Ko si ibikibi ti a le lọ, a maa ń ni awọn ọrẹ. A si dupẹ fun awọn ọ̀rẹ́ wa. Ṣugbọn ohunkan wa nipa awọn ọrẹ ti wọn duro ti ọ nigba ipọnju ati iṣoro ati ni igbati nkan ba dára. Ko si ohun ti a le fi dipo awọn iru ọ̀rẹ́ bayi. Ohunkohun to wu ki awọn ọ̀rẹ́ miran jẹ́, ko si bi a ti ṣe le rọpo iru ọ̀rẹ́ bayi. A ti lọ ọ papọ sinu wọn, ẹ ti di ẹyọkan. Ati àwa, lapapọ, a ń fojusọna fun bibọ Oluwa bi ọjọ tị se n gori-ọjọ. O si nira lati ronu pe iwọ yoo.... a ko le pínya.

8 Ẹsẹ̀ Iwe-Mimọ kan wá sinu ọkàn mi ti mo gbagbọ pe Paulu kọ ti o si sọ ninu Iwe Kọrinti, pe “Ko si ohun

igba isisiyi, tabi ohun igba ti n bọ, tabi awọn agbara, tabi ìhòhò, ebi, ewu tabi eyikeyi ẹ̀dá ti o wa nisisiyi, tabi ìyè, tabi iku ni yoo le yà wà kuro ninu ifẹ Ọlọrun to wa ninu Jesu Kristi.” Bi o ti jẹ wipe ikú papa funrara rẹ, ko le yà wá kuro nitoripe a ti so wa papọ, ninu ọkàn, sinu idapọ nla yi ni ayika Ọrọ, Ọlọrun. Ati iku paapa, ko le ya wa kuro. A ti so wa papọ sinu ayeraye nla yi titi gbogbo ìgbà ati titi gbogbo iran.

9 Ati lẹhin naa, awọn ọmọ, ni owurọ . . . a o lọ si ile-ijọsin, nitootọ, ṣugbọn ni gbogbo ibiti o ba lọ ko si.... kò dabi ile-ijọsin kekere ti o wa ni ibi igun kan. Ohun kan si wa nipa rẹ. Emi ko gbọ ohun agogo kekere naa mọ ati ohun gooro ni apa oke, ni owurọ. Mo ro wipe agogo naa ko dun ni akoko naa nitoripe wọn kò ti kọ́ ohun ti a o gbe akoko naa si.

Ati lẹhinnaa, lapapọ, ni ibiyi ni onka kẹjọ ni opopona Pẹni, nibiti ni bi i ọdun marun-le-lọgbọn sẹyin, ti mo kunlẹ nibiyi ni ibi irà ti mo si kọ ile-ijọsin mi àkọ́kọ́ . . . Bi Jesu Oluwa ti ṣe bami sọrọ lori rẹ. Ati loni, o duro bi i ojubọ-kekere nibiyi. Ati gẹgẹ bi i biriki ati amọ̀ .... o duro bi i ojubọ. Ṣugbọn ni isalẹ ọkàn mi, o jẹ ojúbọ ti yoo duro niwọn igbati mo ba ṣi ni iranti. Ati pe o jẹ . . .

Ohun ti ijọ tumọ si kii ṣe ilé, o jẹ awọn eniyan ti wọn pejọ papọ sinu rẹ lati jọsin fun Ọlọrun. A dupẹ fún awọn ohun wọnyi.

10 Ati nisisiyi, mo ro, boya, bi o ti jẹ wipe akoko wa ti lọ, o ti fẹrẹ lọ tan, a ko si ni akoko mọ ti o ṣẹ́kù, emi yoo kan fun yin ni iroyin diẹ nipa awọn ohun ti o ti ṣẹlẹ. Ati lẹhinnaa, emi yoo ṣe awọn ohùn ti a gbà silẹ nigbati mo ba wa nibiyi. Nitoripe mo ti ṣe ileri fun gbogbo yin, ṣe ẹ ri, pe eyikeyi iwaasu tuntun (fọ́nrán iwaasu ti a gbà silẹ) yoo kọ́kọ́ jẹ lati ibi àga iwaasu yi. Ibi yi ni a o ti maa ṣe gbogbo ohùn iwaasu ti a gbà silẹ, ko ki n ṣe nita lọhun. Bayi, Arakunrin Jim ati awọn iyoku lọ ta awọn ohùn ti a gbà silẹ ninu ipade ati bẹẹbẹẹ lọ. Ṣugbọn ohunkan wà ....nigbagbọgbo ni o maa n dá lori fọnran kan ti o kọkọ jade wà lati ibiyi. Ṣe ẹ ri? Ti ẹ ba wo gbogbo rẹ lati ẹyin wá, ẹ o ri i. Eyi ni ileri ti mo ṣe fun yin, yoo si maa tẹsiwaju ni ọna yì titi ti Oluwa Ọlọrun yoo fi yi i pada.

11 Mo si rò, nisisiyi, pe awọn onibara wa ti wọn maa ń ra awọn ohùn ti a gbà silẹ, ti wọn wà ni gbogbo agbaye....iwaasu kan ti o jade lọ lati ibiyi, ti o kaari gbogbo àgbáyé. Ṣe ẹ ri? Ti o lọ sinu awọn ahéré ati ibi gbogbo, o lọ lati ipasẹ awọn ohun iwaasu ti a gbà silẹ. Ati si awọn keferi ati bẹẹbẹẹ lọ, pẹlu ọpọlọpọ, ati ọpọlọpọ oriṣiriṣi awọn èdè ti a fi tumọ rẹ si. Nitorina mofẹ́, niwọn igbati mo ba wà nibiyi, ti Oluwa bá fẹ́, lati ṣe awọn fọnran iwaasu ti a gba silẹ tuntun. Ati boya ti oluṣọ-agutan kò ba ni ohunkan ti o n gbóná ninu ọkàn rẹ ni aṣalẹ yi, o dára, emi yoo nifẹ lati ṣe gbigba ohun iwaasu silẹ ni aṣalẹ yi.

12 Ati lẹhinnaa, emi yoo lọ si ilu Arkansas ni ọla ati.... tabi ni ọjọ Iṣẹgun dipo, owurọ ọjọ Iṣẹgun, lati lọ ṣe iranwọ ninu agọ-ajọ kekere kan nibẹ pẹlu apejọpọ ẹgbẹ awọn Arakunrin Kristẹni nigbogbo àgbáyé. Mo rò .... tabi boya emi ko pe e daradara bi o ti ṣe yẹ ki emi pe e. O jẹ ohunkan nipa ẹgbẹ apejọpọ Ọkunrin Kristẹni ni orilẹ-ede. Emi ko mọ eyi daadaa. Mo tọrọ gáfárà. O jẹ ohun ti o búrú, ṣe ko ri bẹ ẹ bi? (Mo dupẹ sa.) Ẹgbẹ apapọ awọn Ọkunrin Kristẹni. O si yẹ ki n ti ṣe tan ....bẹrẹ lati ọjọ Isinmi, bayi, ki o si tẹsiwaju. Ṣugbọn emi ko sọrọ loni nitori agọ-iwaasu yi, ki emi ba le wa nibiyi. Ati lẹhinnaa emi yoo ṣetan ni ọjọ Ẹti.... (Ṣe ohun naa ni....sa, ṣe ohun....?) Ọjọ Ẹti ni isin naa pari nibẹ. Emi yoo si gbiyanju lati pada wa ni alẹ ọjọ Abamẹta ki emi ba a le wa nibiyi ni owurọ ọjọ-Isinmi. Ti Oluwa bafẹ́. Emi yoo ṣe gbigba ohùn iwaasu miran silẹ. Ati boya nigba miran, nipasẹ eyi bayi, emi fẹ ṣe gbigba ohun iwaasu silẹ diẹ ṣaaju ki a to pari.

13 Ati lẹhin naa mo n làkàkà fún ilu Baton Rouge ni ipinlẹ Louisiana, fun àgọ-ajọ. Lẹhin naa n o pada wa. Ati lẹhin naa o yẹ ki emi ki o lọ, ni gbogbo ọna, si ilu Anchorage. Ṣe ẹ ri? Ati lati ilu Fairbanks ati ilu Anchorage, fun awọn ẹgbẹ Oniṣowo Kristẹni Ọkunrin lẹkunrẹrẹ ni awọn abala wọnyẹn. Ati lẹhin naa n sẹ́ri pada. Ati ti Oluwa bafẹ́, n o lọ si ilu Chicago ni ọsẹ to gbẹyin ninu oṣu keje.

O si yẹ nigba naa, ni bi I dédé akoko naa, n o gbe awọn ọmọ lọ pada ni kia kia si ilú Arizona, n o si tun pada lati le e wa.... lati le fi wọn si ile-iwe nibẹ. Nitoripe, Charlie, mo ni lati wa nibiyi ni bi ọjọ karun-din-logun oṣu Kẹjọ. Nitorina mo ti fẹ pada ṣaaju akoko naa, ti Oluwa bafẹ, ni ilu Kentucky. Gbogbo awọn eniyan n rẹrin, boya diẹ lara awọn ti wọn ṣẹṣẹ n wa sinu ile ijọsin yi ko mọ ohun ti eleyi tumọ si. Mo ro wipe eyi ko buru lati sọọ lati ibi aga iwaasu, sugbọn igba ti akoko ọ̀kẹ́rẹ́ niyi. Nitorina ti o ba jẹ wipe mo....emi n gbara le eyi, ṣe ẹ ri. Nitorina.... fun bi i awọn ọ̀sẹ̀ diẹ nibẹ fun isinmi mi.

14 Bayi, mo gbagbọ pe . . . Mo ni ohunkan nibiyi ti Billy kọ sinu iwe fun mi, awọn iwe kekere kan. Ọkan ninu wọn si sọ wipe, “Baba mi, Arakunrin Neville fẹ mọ boya iwọ yoo le ya ọmọ meji si mimọ,” Dajudaju....Eleyi dara. Ati bẹni, a o ni isin iya-ọmọ-si-mimọ eyiti.... A le e niwọn bayi. Ati lẹhinnaa, mo rò, a o lo iṣẹju marun-le-logoji ti o kan tabi ohunkan, lori awọn iroyin, lori awọn ohun ti o ti ṣẹlẹ.

Bayi, ọpọlọpọ awọn eniyan ati awọn ijọ ti o jẹ wipe nigbati emi....Eleyi jẹ́ àgọ́-ijọsin ti a ṣi sile. Ko ki ń ṣe ijọ ẹlẹkọ adamọ kan, Ọlọrun yoo si bojuto ti kò ni fi jẹ ijọ ẹlẹkọ adamọ, laelae. Nitori wipe a fẹ jẹ ki ibiyi jẹ ibiti a ko ti ni ofin kankan sugbọn a ni ìfẹ́, a ko ni ẹkọ adamọ ṣugbọn Kristi, a ko ni iwe-ẹkọ kika ṣugbọn a ni Bibeli.

Ati lẹhinnaa, a ko ni ọmọ ijọ, ṣugbọn a ni ìdàpọ, pẹlu ara wa; fun gbogbo eniyan, fun gbogbo ijọ ẹlẹkọ adamọ. Gbogbo eniyan ni a ki kaabọ a si ni idapọ pẹlu Ọrọ̀ Ọlọrun, nibiti gbogbo eniyan le e ti ni imọlara pe a ki wọn kaabọ bi wọn ti ṣe le ni i tó. Ninu ofin ti a duro le lori, a kan nifẹ Oluwa Jesu. A ko si jẹ ẹgbẹ awọn ọ̀jọ̀gbọ́n ninu iwe-kíkà nibiyi. A kan jẹ awọn eniyan ti ìnú wọn mọ ti wọn n gbiyanju lati ka Bibeli ti wọn ko si fi itumọ kankan si yatọ si ohun ti O sọ nikan. Nikan ....

15 Mo gbagbọ pe Ọlọrun yoo da aye lẹjọ ni ọjọ kan pẹlu Bibeli. Nisisiyi, ti wọ́n ....Yoo da aye lẹjọ. Ti ko ba si si oṣuwọn kankan ti yoo lo lati da a lẹjọ, bawo ni awọn eniyan yoo ṣe mo ohun ti wọn yoo ṣe? Ṣe ẹ ri? Yoo jẹ Ọlọrun.... O ko le ri aiṣododo kan pẹlu Ọlọrun. Ọlọrun gbọdọ ni ohunkan fun oṣuwọn Rẹ, eyiti O fi maa n da awọn eniyan lẹjọ. Nitorina, ti o ba ṣe idajọ pẹlu eto ijọ Aguda ti Romu, lẹhin naa ijọ Giriki (Ijọ Aguda, ti o jẹ ipilẹ) ati ọpọlọpọ bi irú awọn ijọ bayi ti ṣègbe, ati gbogbo agbaye pẹlu. Ti o bạ se idajọ rẹ pẹlu eto Ijọ Aguda Giriki ti o jẹ ipilẹ, ti ko sị se e pẹlu eto Ijọ Romu, lẹhinnaa Ijọ Romu ati gbogbo awọn ijọ iyoku ti ṣegbe. Ti o ba se idajọ rẹ pẹlu eto ijọ awọn ara Luther, lẹhin naa ijọ awọn alagba ti ṣegbe. Ti o ba ṣe idajọ pẹlu eto ijọ awọn Alagba, lẹhin naa ijọ awọn ara Luther ati ijọ Onitẹbọmi ti ṣegbe. Ṣe ẹ ri? Nitorina ti o bạ se idajo rẹ pẹlu eto ijọ awọn Pentikọsti, lẹhin naa gbogbo awọn ti wọn yatọ si ijọ Pentikọsiti ti ṣegbe.

16 Ṣugbọn ko lo ijọ kankan lati ṣe idajọ rẹ, ninu èrò ti ara mi, o jẹ nitoripe iyatọ pupọ ni o wa ati ìdàrú-dàpọ ni o wà. Ṣugbọn yoo ṣe idajọ rẹ̀ ....Bibeli sọ wipe, “Yoo ṣe idajọ aye lati ipasẹ Jesu Kristi.” Bayi, eleyi ba Iwe-Mimọ mu. Nisisiyi....Bibeli si sọ wipe “Ni atetekọṣe ni Ọrọ̀ wà, Ọrọ si wà pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa. A si sọ Ọrọ naa di ara, o si n bá wa gbé .... Oun kannaa ni àná, ni òní ati titi lae.” Nitorina, Oun ni Ọrọ naa. Eleyi si ni Kristi ti a kọ silẹ ninu iwe. Ati ninu iwe ti a kọ nipa òpin-aye si Ijọ Aguda, iwe Ifihan si awọn ará ijọ̀ Protẹsitanti....ninu ori keji-le-logun nigbati a kọ iwe yi parí, Jesu funrara Rẹ sọ wipe, “Ti ẹnikẹni bá yọ ẹyọ ọ̀rọ̀ kan kuro ninu iwe yi tabi ti o ba fi ẹyọ ọrọ kan kún un, ẹni naa.... a yọ ipa rẹ kúro ninu iwe ìyè.” Nitorinaa Emi .... . . Ìdí ti a fi gba eleyi gbọ́ ni wipe .... O sọ Ọ gẹlẹ …. Ko si ohunkohun.... O le ṣe awọn ohun ti Oun kò kọ silẹ nibiyi, a mọ eleyi. Ṣugbọn niwọn igbati a ba duro ti ohun ti O ti kọ silẹ, eleyi yoo dara.

17 Ati nisisiyi, ni yiya ọmọ si mimọ, ọpọlọpọ ninu awọn eniyan, awọn ara ijọ Mẹtọdisi maa n wọ́n omi le wọn lori ni. Mo si ro wipe wọn ni isin ounjẹ-alẹ-Oluwa akọkọ ninu Ijọ-Aguda tabi Ijọ Luther pẹlu bi i igba ti wọn ba pe ọmọ ọdun mejila, wọn yoo si ṣe isin iribọmi fun wọn nigbati a ba bi wọn, mo ro wipe a maa ń wọ̀n omi si ori awọn ọmọ ọwọ. Mo si ro wipe eleyi jẹ ki ijọ Nazarẹni yapa kuro lati inu ijọ Mẹtọdisi ni ọpọlọpọ ọdun ṣeyin, ṣiṣe iribọmi fun awọn ọmọ-ọwọ́. Mo ro pe eyi ni otitọ Arakunrin Brown. Mo gbagbọ pe eleyi lo jẹ ki ipinya wà laarin ijọ Mẹtọdisiti ati ijọ Nazarẹni nitori ijọ Nazarẹni ko gbagbọ ninu ṣiṣe iribọmi fun ọmọ-ọwọ. Ṣugbọn fún àwa, ni Àgọ́ ijọsin nibiyi, awa yoo duro ti ohun ti Bibeli sọ .... Kò si ibikibi ninu Bibeli ti wọn ti wọ́n omi si ẹnikẹni lori, ki a maa si wa sọ nipa ọmọ-ọwọ, wọn ko ṣe bayi fun agbalagba paapa. Ṣugbọn wọn .... Bibeli sọ wipe, ibikan ṣoṣo ninu Bibeli ti o wà fun awọn ọmọde “Wọn gbé awọn ọmọ-ọwọ tọ Jesu wa, ki o ba le gbe ọwọ le wọn ki O si bukun fun wọn.” O si sọ wipe, “Ẹ jẹ ki awọn ọmọde wa si ọdọ Mi, Ẹ ma si ṣe dá wọn lẹ́kun, nitori iru wọn ni ijọba Ọlọrun.”

18 Nisisiyi, nitorina, a mọ wipe ọwọ́ wa jẹ alaiyẹ, oluṣọ-agutan ati emi, tabi eyikeyi oluṣọ-agutan, lati le gba ipò ọwọ Jesu Oluwa. Ati ti o ba jẹ wipe o wà nibiyi ni owurọ yi awọn obi ọmọ yi yoo mu ọmọ naa tọ Kristi wá. Ṣugbọn nitoripe a wa nibiyi ti a si duro gẹgẹ bi i asọju Rẹ, wọn mu awọn ọmọ naa tọ̀ wá wá. A si yà wọn si mimọ fun Oluwa nipa gbígbé awọn ọwọ wa le wọn nipa gbigbọran si Ọrọ nla Rẹ ati iṣe Rẹ. Nitorina bayi ni a sị se ń ya awọn ọmọ kekeke si mimọ.

Mo ro boya awọn iya diẹ le wa nibiyi pẹlu awọn ọmọ wọn, ti a ko ti ya wọn si mimọ fun Oluwa, ti wọn si le nifẹ pe ki wọn wa pẹlu awọn iya wọnyi tabi awọn baba wọnyi, ti wọn fẹ ya wọn si mimọ. A o gbe wọn wa si ibiyi, a o si gbe wọn si iwaju Ọlọrun, a o si gbadura fun wọn, a o sọ fun Oluwa pe a gbe ọwọ wa le wọn, ni irọpọ Oun funrara Rẹ. Eleyi ni o si sunmọ Iwe-Mimọ julọ ti emi tii ri! Bayi, o le mu iwe-kika rẹ jade ki o si wadi ohun ti awọn ẹgbẹ ọmọkunrin kan ti sọ, ṣugbọn ohun ti Ọrọ naa sọ ni emi n sọ itumọ rẹ. Ṣe ẹ ri? Mo si ro pe mo ti ṣalaye eleyi, daada yekeyeke ohun ti o tumọ si.

19 Bayi, ti atẹduru (ṣe iwọ ni atẹdùrù, arakunrin? Ṣe iwọ yoo wá sibiyi, se eleyi kọ jẹ ohun to buru, ninu ijọ mi, ki emi maa bere “Ẹniti o jẹ atẹduru?” (Mo fẹrẹ le e maa kan ilẹkun.) O dara. Wọn yoo kọ kọrin kekere naa wọn yoo tẹ dùrù si i.

Mu wọn wa, mu wọn wa,

Mu awọn ọmọde wa sọdọ Jesu.

Ati nigbati awọn apejọpọ ba n kọrin yi, ẹ jẹ ki a dide duro lori ẹsẹ wa. Si jẹ ki awọn iya ati awọn baba ti wọn fẹ gbe awọn ọmọ kekeke wa ki wọn maa bọ̀ bayi, ki a si kọrin, O dara.

Mu wọn wa, mu wọn wa,

Mu awọn ọmọde wa sọdọ Jesu

20 Bayi oluṣọ-agutan. Nisisiyi a ni ọmọde kan nibiyi ti o n sùn ati nigba miran wọn “amin” oju wọn ko rẹrin a si loye wipe ọmọde ni wọn. Kini orukọ rẹ, sa? William Henry Vincent. Ati orukọ ọmọbinrin kekere rẹ? Tina Maria Vincent. Olufẹ kekere niyi ti o sùn si ejika baba rẹ̀. Ṣe emi le gbe e dani? Kristiana emi ko le dipo baba rẹ nibiyi. Ẹ jẹ ki - ṣe ẹyin yoo gbe ọwọ yin le ọmọ naa. Ẹ jẹ ki a tẹ ori wa ba.

Baba wa ọrun, a n wa sibi itẹ Rẹ loni eyiti o kọja igbagbọ wa. Gbé wa soke ju oṣupa, ju awọn irawọ, ju gbogbo awọn ẹda oju-ọ̀run lọ si iwaju Olodumare. A mu ọmọ kekere ti o lẹwa yi wa. Awa kò mọ ohun ti a gbé lọwọ yi Oluwa, o le jẹ iranṣẹ nla fun Ọ ni awọn ọjọ to n bọ̀. A gbagbọ pe yoo ri bẹ. Ṣugbọn baba ọmọ yi ti mu ọmọ kekere naa tọ̀ wá wá pe ki awa le gbe ọwọ wa le e ti awa si ti jẹwọ pe iranṣẹ Rẹ ni a jẹ ti a si duro ni ipò Rẹ titi ti Iwọ yoo fi pada wá. Nigbana Iwọ yoo gbakoso ohun gbogbo. Titi ti yoo fi di igba naa Oluwa, a gbọdọ sin Ọ pẹlu otitọ-ọkan ati ododo pẹlu ọwọ wa ti a si gbe e le ọmọbinrin kekere yi lori, a bukun fun un ni orukọ Jesu Kristi Oluwa. A gbagbọ pe iwọ yoo fun un ni ẹ̀mí gigun, ti Jesu ba fa bibọ Rẹ sẹyin, jẹ ki o di ojiṣẹ nla fun Ọ. Bukun fun ile naa ti a o ti tọ ọ dagba. Jẹ ki a tọ ọ dagba ninu ẹ̀kọ́ Ọlọrun, ki o si sin Ọ ni gbogbo ọjọ aye rẹ̀. Bukun fun awọn obi rẹ, si jẹ ki wọn wa laaye ki wọn si ri ọmọ yi bi yoo ti jẹ ohun èlò ọla fún Oluwa nitori ohun ti wọn ṣe ni oni ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

Ki Ọlọrun ko bukun fun ọ.

Ki Ọlọrun kó bukun fun ọ, sa. Kini orukọ rẹ .... [Arabinrin kan ń ba Arakunrin Branham sọrọ] Arabinrin Tabet niyi, Teresa. Emi ko mọ boya awa yoo le gbe Teresa tabi awa ko ni le gbe e. Emi ko ro bẹ. Oun mọ dara julọ.

O dara, ẹ jẹ ki a tẹ ori wa ba.

Baba wa ọrun, bi a tị se gbe ọwọ wa le arabinrin ọmọ kekere yi ti a ṣẹṣẹ yà si mimọ fun Ọ, awọn obi ọmọ naa fẹ ki a ya ọmọ kekere yi si mimọ pẹlu. Jẹ ki ore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa duro si ori ọmọ naa, ki o si fun un ni ẹ̀mí gígùn, igbé-ayé ibukun ti yoo jẹ isin fun Ọ, ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

Ki Ọlọrun ko bukun fun ọ nisisiyi, ki Ọlọrun ko bukun fún gbogbo yin. Ẹ jẹ obi ti o ri ore-ọfẹ nla gbà, ni owurọ yi, lati le ni awọn ọmọ kekere meji wọnyi.

21 Kini orukọ rẹ? [Baba naa sọ wipe, “Joe William Cartwright”] Joe William Cartwright. O mu aburo rẹ ni owurọ yi. Mo ro, o dara. Nisisiyi, ti o ba .... gbogbo yin .... O dara, O le mu u dani ti o ba —— ti iwọ ba dipo, Iya-afin Eleyi dara, Josefu, wa si oke nibiyi. O dara. O si le e mu u dani, ti o ba fẹ́.

Baba wa ọrun, a mu eyi wa si ọdọ Rẹ, Josefu Willian Cartwright kekere yi. Baba rẹ duro ni owurọ yi lati fi ọmọ ti Iwọ ti fi fun un pada fun Ọ, fun igbesi-aye isin. Ọlọrun, bukun fun ọmọ kekere yi, si jẹ ki o ni ẹmi-gigun ni ayé, ki o ni ilera pipe, ki o jẹ alagbara, ki o si di ojiṣẹ Ọlọrun nla fun Ọ. Bukun fun baba ati iya rẹ, ile ti a o ti tọ ọ dàgbà. Jẹ ki Kristi jẹ alejo naa ti a ko fi oju ri ni gbogbo igba. Bi a tị se fi ọmọ kekere yi fun Ọ, fun igbesi aye isin, ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

Ki Ọlọrun ko bukun fun ọ, Arakunrin Steve Cartwright.

22 Ọmọbinrin kekere? [Arabinrin kekere sọ wipe, “Bẹni sa.”] Iya-afin? [“Pam Lewski.”] Sylvia Shippy.

Baba wa Ọrun, a gbé ọwọ wa le ọmọbinrin kekere yi lori, gẹgẹ bi awọn olufẹ rẹ ti mu u wa sibiyi ni owurọ yi, ti a si duro ni ibi pẹpẹ. Jẹ ki ibukun ti yoo wa si ori rẹ, ti Jesu Oluwa ba gbe ọwọ ti o ni apá-ìṣó Rẹ le ọmọ naa lori, jẹ ki awọn ibukun wọnyi ba le ọmọ kekere yi lori. Bukun fun un nisisiyi, si jẹ ki o ni ẹmi-gigun ni ayé, ki o gbe igbesi-aye ti o ni ìdùnnú, ki o si jẹ iranṣẹ fun Ọ. Ki O si bukun fun ile rẹ, bukun fun awọn obi rẹ, bukun fun awọn olufẹ rẹ. Ni orukọ Jesu Kristi ni a ṣe ohun yi, gẹgẹ bi i Bibeli. Amin.

Mo fi ibukun fun Ọ ....? Ibukun ni fun ọ ....?. . .

23 Yoo jẹ akọrin kan ni ọjọ iwaju. Ki ni orukọ rẹ? [Arakunrin naa sọ wipe, “Roy Allen Myer”] Roy Allen Myer. Mo wipe, yoo jẹ akọrin kan ni ọjọ iwaju.

O jẹ ki n ranti, mo lero pe eleyi ko koro lati gbọ, ni ile-ijọsin yi, ni ọjọ kan emi n ba ara ilu Indian kan sọrọ. O ni ọmọ kekere kan ti o duro nibẹ, mo si sọ nigba naa wipe, “O jẹ ọmọ kekere ti o ni iwa tútù. O ni iwa tútù.”

Oloye naa si n wo mi, fun iṣẹju diẹ. Lẹhin naa o bojuwo ilẹ, o si sọ wipe, “ṣugbọn, kii ṣe ọkunrin, obinrin ni.”

Mo ro pe, bo ṣe ri niyẹn sibẹ.

Kini orukọ ọmọkunrin naa .... [Arakunrin naa sọ wipe, “Roy Allen”] Roy Allen. Allen ni orukọ keji ti o n jẹ [Myer.“] Myer [”Roy Allen Myer.“] Roy Allen Myer. O jẹ ohun kekere to lẹwa.

Baba wa ọrun bi a ti ṣe gbe ọwọ le ọmọde kekere yi, ati ninu Bibeli wọn sọ wipe wọn mu awọn ọmọkekere wa si ọdọ Rẹ, ki Iwọ ba le gbe ọwọ le wọn ki O si bukun fun wọn. Ohun ti a si n ṣe niyi ni iranti si ohun nla ti Iwọ ṣe ni orilẹ-aye. Bukun fun ọmọ yi, awọn obi rẹ. Jẹ ki ile naa di ibi adura nigba gbogbo, ibi alafia. Si jẹ ki ọmọbinrin kekere yi ni ẹmi gigun, ki igbesi-aye rẹ ki o dùn ki o si jẹ ojiṣẹ Rẹ ni gbogbo awọn ọjọ. Si jẹ ki okun ẹbi naa ki o maa ja laelae. Ninu Ogo, jẹ ki gbogbo ẹnikọọkan ninu ẹbi naa pejọ papọ yika Itẹ nla Ọlọrun, ni ọjọ naa, jẹ ki ibukun nla Rẹ wa lori ọmọ naa, ẹniti a bukun fun ni orukọ Jesu. Amin! …?....

Ohun kekere .... aburo obinrin kekere rẹ, Rebekah.

Baba ọrun, a gbe ọwọ wa le Rebekah kekere a si bukun fun un, pẹlu, ni orukọ Oluwa Jesu, bii igba ti o ba n lọ si ibi omi, ti o n lọ si ibi-adagun omi. Mo si gbẹkẹle, Oluwa, pe ọjọ naa yoo de nigbati o ba dagba, ti o si de ọjọ ori-ti eniyan ti mọ ohun buburu yatọ, pe yoo mu iduro rẹ, ti yoo si rin lọ si ibi omi adagun naa nibẹ, ti yoo si ṣe iribọmi fun imukuro ẹṣẹ rẹ, ni orukọ Jesu Oluwa. Ṣe eyi, Baba. Nisisiyi bukun fun, pẹlu arabinrin rẹ kekere. Jẹ ki o ni ẹmi-gigun, ki igbesi-aye rẹ si dùn, ki o si sin Ọ. Amin.

Ki Oluwa bukun fun un. Oluwa bukun ọ.

24 Oun niyi? [Mama rẹ sọ wipe, “Jacqueline Grenault.”] Jacqueline Grenault kekere, ọmọbinrin kekere, ti o lẹwa miran.

Baba wa ọrun, a gbe ọwọ wa le ọmọbinrin kekere yi ni iranti Jesu Oluwa nla naa, Ẹniti o gbe ọwọ Rẹ le awọn ọmọde ti O si bukun fun wọn. Si jẹ ki ibukun wa si ori ọmọ naa, gẹgẹ bi i wipe ọwọ Rẹ gangan ni O wa ni ori rẹ, loni. Ti o ba jẹ wipe Iwọ wa ni aye nibiyi, ninu agọ-ara ti a le foju ri, iya rẹ yoo mu ọmọ naa wa si ọ̀dọ̀ Rẹ. Ṣugbọn awa, gẹgẹ bi ìríjú Rẹ, o wa si wa, lẹyin naa, Baba. A si bere pe ki o bukun fun ọmọ yi, ẹniti a ti bukun fun. Ni orukọ Jesu Kristi, jẹ ki o ni ẹmi-gigun, ki igbesi-aye rẹ dun si iṣẹ isin Rẹ. Bukun fun ilé rẹ, ti a o ti tọ ọ dagba, jẹ ki o jẹ ile adura nigba gbogbo, ni orukọ Jesu. Amin.

25 Ki Oluwa bukun fun un. Ṣe o ni awọn meji? [Arabinrin naa sọ wipe, “Mo ni awọn ọmọbinrin meji. Ekeji si wa nibiyi, o si ti wa, pẹlu, arakunrin.'] O dara. Nisisiyi, ọmọkunrin kekere yi jẹ́ .... [James David.” James David. [Humes.“] Humes. Mo ro pe emi mọ ọ, Arabinrin Humes. O jẹ akiriwaasu, iwọ ati ọkọ rẹ. ṣe ọkọ rẹ wa pẹlu rẹ, ni owurọ yi? O dara, ki Ọlọrun ko bukun fun Arakunrin Humes. O sọ wipe, O daju pe o ni awọn ọmọ kekeke ti o dara. Ṣe Dafidi niyi? Eleyi si jẹ ..... [James David ati Joseph! ...?.... ilu Florida ...?....”] mo ṣẹṣẹ n ba arabinrin kan sọrọ ni ti o wa lati ilu Florida, ninu ibi ti mo ti n kẹkọ ni owurọ yi. Ọmọkunrin kekere yi, nigbati o wa .... Wọn wa lati ilu Florida. Nigbati o wa nibẹ, ọmọkunrin kekere naa, ọdọmọkunrin kekere kan, o ri kekere, ọmọ kekere ti ko sanra naa lọ si ẹyin ile, o si n woke, o jẹwọ pe oun ri Jesu.

Nisisiyi, ẹni yi ni David Humes kekere. A gbe ọwọ wa le e, ni yiya si mimọ fun igbe-aye isin fun Jesu Kristi. Tẹsiwaju ibukun Rẹ lori ile naa.

[Alafo wa ninu ohùn ti a gba silẹ]

26 Ọgbọn ọdun sẹyin mo duro ni ẹnu ọna ile-iwe kan ni ibiyi ni ibi oke ilu Utica ṣe emi jẹ́ mọ wipe ọmọkunrin kekere kan, ti o maa n tọ̀, ti wọn maa n woju ara wọn pẹlu itiju, pe ni ọjọ kan emi yoo gbe ọwọ le ọmọ ọmọ rẹ lati ya a si mimọ fun Oluwa Olọrun. Gba Johanu kekere ni owurọ yi Oluwa gẹgẹ bi iranṣẹ fun Ọ. Baba ati iya rẹ fi tọkantọkan mu ẹbun naa pada wa fun Ọlọrun ohun ti o ti fi si ikawọ wọn lati tọ́ju. Si jẹ ki wọn ni igbesi aye okun ati ilera pipe ati agbara ati ipinu ninu Kristi. Nisisiyi, a fi ọmọkunrin kekere yi fun Ọ ni orukọ Jesu Kristi fun igbesi aye isin. Jẹ ki o ni ẹmi-gigun ki o si sin Ọ.

Ṣe a ti ya ọmọbinrin kekere yi si mimọ? Kini orukọ rẹ? Carol. Bẹẹ gẹlẹ lori Carol kekere yi, a gbe ọwọ wa le e, a si ya a si mimọ fun iṣe-isin fun Jesu Kristi. Ọlọrun bukun fun un. Jẹ ki o ni ẹmi gigun pẹlu idunnu. Jẹ ki o jẹ iranṣẹ fun Ọ ni gbogbo awọn ọjọ aye rẹ. Ṣe eyi Oluwa. Bukun fun ile rẹ. Jẹ ki o jẹ ibi adura ati igbagbọ nigba gbogbo. Mo fi ọmọbinrin kekere yi fun Ọ ni owurọ yi lati inu ọkan baba ati iya rẹ ti wọn duro si ibi pẹpẹ kekere yi ni orukọ Jesu Kristi Amin.

27 Ọmọkunrin kekere kan. Baba wa ọrun, baba awọn ọmọ kekere yi mu awọn ọmọ yi ni ọwọ rẹ nisisiyi, ohun ini kekere naa ti o fi fun un gẹgẹ bi ọmọ. Jẹ ki o jẹ ọkunrin ọlọgbọn gẹgẹ bi i Jakọbu ninu Bibeli. Mo gbadura pe Iwọ yoo fun ni ẹmi-gigun pẹlu igbesi aye alafia, Oluwa, si jẹ ki o dide, ti ọjọ-ọla ba wa, jẹ ki o hùwa gẹgẹ bi Ọrọ Ọlọrun. Ṣe eleyi fun wa Baba ni iranti ohun ti Jesu Kristi Oluwa ṣe nigbati O wa lori ilẹ aye yi. Mo gbe ọwọ mi le Jakọbu kekere, mo si ya a si mimọ fun iṣẹ-isin Ọlọrun ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

Oluwa Ọlọrun ni ori ọmọkunrin kekere yi, Gary Gene Adams, jẹ ki ibukun Jesu Kristi wa ni ori rẹ, bi a ti se gbe ọwọ wa le e, bi a ti ya igbesi-aye kekere yi si mimọ fun Ọ. Bukun fun ile rẹ, bukun fun awọn obi rẹ. Jẹ

ki o ni igbesi-aye ẹmi gigun pẹlu idunu ati igbesi-aye isin fun Ọlọrun wa ati Ọlọrun rẹ Ẹniti a fi fun bayi ni orukọ Jesu Kristi. Amin. Ibukun ni fun ọ.

28 Bayi, mo ro wipe eleyi ti yanju iyẹn, nisisiyi. Bayi, a ko gba akoko rara a ti wa ni agogo mọkanla. Bayi, ṣe o mọ̀, emi kan le rò, bi mo ti ṣe ri awọn iya wọnyi, ti wọn ń bọ niwaju, ati awọn baba pẹlu awọn ọmọ wọnyi .... Mo le ronu nipa Josẹfu ati Maria ni owurọ ọjọ ti a ya Jesu Oluwa si mimọ.

Arakunrin Kidd, mo ń ṣe ifọ̀rọ̀wáni-lẹnuwo kekere kan pẹlu ẹnikan ninu ọ́físì, ṣugbọn mo gbọ ìtara rẹ ni owurọ yi, ni ita nibiyi eniyan bi i iru ọjọ ori rẹ. Mo si rò pe o ń sọ fun wa bi Oluwa ti ṣe wò ọ sàn .... awọn apejọpọ. Mo fẹrẹ le ba ọkọ-ayọkẹlẹ mi jẹ ni owurọ ọjọ kan nigbati mo ń gbiyanju lati de ọdọ agbalagba kan .... O jẹ ojiṣẹ-Ọlọrun ti o ti di arúgbó.

29 Mo kan rò. Ọkunrin yi .... (iyawo rẹ kekere, nibiyi), o ti ń waasu ihinrere ṣaaju ki a to bi mi. O ti ń waasu ihinrere yi ni ibi awọn ori òkè ati pẹtẹlẹ ti ilu Kentucky ati Tennessee, nibiti awọn ti o ń wa kusa èédu .... Ti wọn si ná gbogbo ohun ini wọn. Wọn si ń gbe igbesi-aye wọn laisi ohunkohun lati jẹ. Ati iyawo rẹ kekere yi, nibiyi, yoo gba aṣọ fọ nibiti wọn ti n fọ aṣọ fun bi i ogun tabi ọgbọn owó ṣile fun ọjọ kan, lati le ràn ọkọ rẹ lọ si ilẹ ihinrere lati lọ waasu ihinrere. Eleyi to fun eniyan kan ki o kigbe fún ayọ̀, a bi bẹẹ kọ?

Ati lẹhin naa ki eniyan ronu, pe o sun silẹ nigbati awọn dokita akọṣẹ-mọṣẹ ti o dara julọ sọ wipe, “O ń kú lọ. O ni aisan àtọ̀sí ti o ni jẹjẹrẹ ninu gbogbo àgọ́ ara rẹ̀. Ko le gbe aye mọ̀ ayafi fun awọn wakati diẹ, ati fun ọjọ kan tabi meji gbòòkì.” Eleyi si jẹ fun bi ọdún meji tabi mẹta sẹyin. Ọdun mẹta sẹyin, oun si niyi ni owurọ yi pẹlu ilera pipe ti ara rẹ si ya daadaa, ti o si ń fi ogo fun Ọlọrun. Nigba naa, ọmọ ọdun melo ni ọ nigbati a wo ọ san, Arakunrin Kidd? O to bi ọmọ ọdun melo nigbati Ọlọrun .... Ọmọ ọdun melo ni nisisiyi? [Iya-afin Kidd sọ wipe, “ọmọ ọdun mẹta-le-ni-ọgọrin, yoo pe ọmọ ọdun mẹta-le-lọgọrin ni oṣù kẹjọ.] Ọmọ ọgọrin ọdun. Eleyi dara, o fẹ́rẹ̀ to ọmọ ọgọrin ọdun nigbati Ọlọrun wo o san. Ni bayi, ṣe Ọlọrun maa n ṣe itoju awọn arugbo bi? Dajudaju O maa n ṣe bẹẹ. Bẹẹni Sa!

30 O wo Abrahamu sàn nigbati o jẹ ọmọ ọgọrun ọdun, ti Sarah si jẹ ọmọ aadọrun ọdun. Wọn si bi Iṣmaẹli - tabi mo tọrọ aforiji, Isaaki. Ṣe eleyi jẹ otitọ? Inu wa dun fun eleyi.

Bayi, ẹ jẹ eniyan ti o dara, mo le ba yin sọrọ bi eleyi titi di owurọ. Ṣugbọn ẹ jẹ ki a ka lati inu Ọrọ iyebiye ati lẹhin naa ki a lọ sinu isin taara. Bayi, mo rò, ti o ba jẹ ifẹ Ọlọrun, ń o nifẹ lati royin awọn ohun ti o ṣẹlẹ fun yin. Ati lẹhin naa ni aṣalẹ yi, ti Oluwa ba fẹ, mo fẹ sọrọ lori akori .... mo fẹ ki a gba ohùn naa silẹ ki a ba le gbe e si ita. Ti .... ati ti iwọ ba nifẹ lati wa gbọ, eleyi dara. Lẹhin ti oluṣọ-aguntan ba ti ṣetan pẹlu iwaasu rẹ lẹhin naa emi yoo ni temi .... emi yoo ṣe gbigba ohùn silẹ. Emi fẹ waasu rẹ lori akori Itansan Pupa Ina Bibọ Rẹ. Bi ọkan ninu awọn itansan ina naa tị se wa ni ọ̀dọ̀ wa bayi, ni lọwọlọwọ bayi. Mo si fẹ sọrọ lori eleyi ni aṣalẹ yi. Itansan Pupa Ina Bibọ Rẹ.... O wà nibiyi, O wà ni lọwọlọwọ, ni bayi bayi. Awọn àmì naa. Ọkọ oju-irin naa ti wa ni ibùdókọ̀.

31 Iwe Numeri, ori kẹrin-din-logun, si iwọ ti o fẹ ṣi i ti o si fẹ ka a.́ Eleyi jẹ Ọrọ ayeraye nitori naa ẹ jẹ ki a ka A tọ̀wọ̀tọ̀wọ̀. Mo fẹ ka ẹsẹ meji ninu iwe Numeri ori kẹrin-din-logun, ẹsẹ̀ kẹta ati ẹsẹ kẹrin, lati le ni ipilẹ kekere kan lori ohun ti mo nifẹ lati sọ.

Ati nisisiyi, ti awọn ti o n gba ohun-silẹ ko ba ti ṣetan, o wu mi pe ki wọn bẹrẹ bayi. Tabi ki wọn tun un ṣe ki ibi apa ibiyi le pẹlu awọn ohun ti a o gba silẹ ti a o si fi sita. Eleyi yoo lọ si ita ti iwọ bá fẹ́ .... Ṣe iwọ yoo tun ẹrọ naa ṣe si ibi ti apa ibiyi wa, ni apa ibiyi, ṣe ẹ fẹ ya eleyi sọtọ kuro ninu gbogbo isin iwaasu naa? Ṣe ẹ ri, eleyi jẹ ohun tuntun kan. Nisisiyi, ti ẹ ba le fo ibiyi nisisiyi tabi ohunkohun to wù ti ẹ ba fẹ ṣe. O dara, lẹhin naa, a o .... Ṣe ẹ fẹ ki emi ki o fo ibiyi ni iṣẹju kan ati lẹhin naa ki emi ki o tún pada sibẹ, nitorina eleyi yoo fun yin ni ami ibiti ẹyin yoo ti bẹrẹ padà? Tabi ṣe ẹyin le e bẹrẹ lati ibẹ ni ọ̀nàkọnà? Ẹyin yoo bẹrẹ ni ọnakọna. O dara, eleyi dara.

32 Nisisiyi, a o ka lati inu Iwe Numeri, ori kẹrin-din-logun ẹsẹ kẹta ati ẹkẹrin.

Nwọn si ko ara wọn jọ pọ̀ si Mose ati si Aaroni, nwọn si wi fun wọn pe, o to gẹ, nitoripe gbogbo ijọ li o jẹ mimọ, olukuluku wọn, OLUWA si mbẹ laarin wọn, nitori kili ẹyin ha ṣe n gbe ara yin ga ju ijọ OLUWA lọ?

Nigbati Mose gbọ́, o doju bolẹ;

Baba wa ọrun, bukun fun awọn ọrọ diẹ wọnyi. Si jẹ ki aṣaro ọkan wa, ati èso ètè wa jẹ itẹwọgba ni oju rẹ, ni orukọ Jesu ni a gbadura. Amin.

Mo fẹ mu eyi fun akori, fun ohun ti mo nifẹ lati sọ ni owurọ yi. Diduro Laarín Àlàfo!

33 Ni akoko ti a n sọrọ nipa rẹ tabi ti a n kà .... Ni tootọ, gbogbo wa ni a loye pe o jẹ igbati Dathani ati Kora ti wọn ti ṣe ipinnu pe awọn yoo ṣe idiwọ si iṣẹ-iranṣẹ ti Ọlọrun ti gbé le Mose lọwọ, ti wọn si sọ wipe “O yẹ ki o

gba gbogbo apejọpọ laaye lati jẹ ki wọn ṣe eyi ati tọ̀un. Gbogbo wọn ni wọn jẹ mimọ.” Ọlọrun si ti pasẹ fun Mose pe ki o dari awọn eniyan naa lọ si ilẹ Ileri. Wọn si sọ wipe, O gbé gbogbo rẹ̀ si ori ara rẹ lati ṣe ohun pupọ. Iwọ ti o n gbiyanju lati pe ara rẹ ni mimọ julọ laarin gbogbo apejọpọ ti o jẹ wipe iwọ nikan ni o maa n sọrọ.“

Eleyi ko si mu inu Ọlọrun dùn ràrá titi ti o fi sọ fún Mose wipe, “Ya ara rẹ kuro sọtọ laarin wọn. Emi yoo pa gbogbo apejọpọ naa run, Emi yoo si bẹrẹ iran tuntun miran pẹlu rẹ.” Mose si ṣubu siwaju Ọlọrun, o si sọ wipe .... O ni lati wa si ori rẹ. Ṣe ẹ ri?

34 Bayi, loni, ti Ọlọrun ba fẹ pa eniyan run .... ti akoko kan ba si wà .... Nigbati ẹ̀ṣẹ wa ba sú Ọlọrun (Nigba gbogbo ni a maa n kùna) .... tani yoo duro bi Mose, loni, fun awọn eniyan? Nibo ni a o ti ri eniyan ti yoo duro, tabi ti o le duro, ti Ọlọrun yoo tẹwọ́ gbà gẹgẹ bi o ti se fun Mose? Igbesi-aye Mose ni aye ṣe pataki pupọ niwaju Ọlọrun ti o fi jẹ wipe, Ó dá ibinu Ọlọrun dúro. Ọlọrun ko si le e da Mose kọja. Eleyi maa n jẹ àdìtú fún mi nigbogbo igba titi o fi jẹ wipe .... . ni ọjọ kan, ninu ifihan ninu Iwe-Mimọ, ero yi wa sinu ọkan mi, pe .... Ṣe ẹ ri, Mose ninu iṣe ní gbogbo ọ̀nà jẹ arọpo. O jẹ apẹrẹ Jesu Kristi.

35 Ati nigbati Ọlọrun fẹ gba gbogbo ẹmi agbaye patapata, ki o si pa a run, ati gbogbo awọn ẹlẹṣẹ (ti o si da wọn lẹbi iku) .... Kristi kú fun gbogbo wa. Ọlọrun ko si le e dá Kristi kọja, nitori O jẹ Ọmọ Rẹ̀. Lẹyin naa, Jesu fi ara rẹ lelẹ lọfẹ, ki O baa le san owo ọna naa nigba naa .... Mose ko le ṣe eleyi. Mose kò ni ẹjẹ̀ ṣugbọn ẹ̀jẹ̀ eniyan ni o ni, gẹgẹ bi awa. Nitorina, nigba naa, ẹjẹ rẹ ko lee ṣe .... Ko le tó fun eyi. Ṣugbọn Jesu bi o ti jẹ wipe o jẹ ẹjẹ Ọlọrun funrara Rẹ, ẹjẹ Ọlọrun ti a dá .... Ọlọrun kàn yàgò fun gbogbo ìran eniyan nigba naa, nitori ẹ̀ṣẹ̀, nitori wipe a gbé gbogbo rẹ le E ni ori. O si lọ si Kalfari, O si kú kuro niwaju Ọlọrun, O si jiya. A si sọ Ọ sinu ọrun apadi nitori wipe o di ẹṣẹ, a gbe .... ẹ̀ṣẹ̀ wa ni ori Rẹ. Ati nibẹ ni O di ẹniti o gbe gbogbo ẹrù wa, O si gbe gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wa lọ si Kalfari, ati lati Kalfari lọ si ọrun-apadi, Ọlọrun si gbe E dide ni ọjọ kẹta fun iwẹnu ẹṣẹ wa.

36 Ati ni oni, Oun nikan ni alagbawi laarin Ọlọrun ati eniyan, a si dari ẹṣẹ wa ji lọ́fẹ ati idariji. Ọlọrun ko mọ rara pe a dẹṣẹ rí. A fi ẹ̀ṣẹ̀ wa sinu okun ìgbàgbé ti a ko si ni ranti rẹ mọ́ rara. A ko le ṣe eleyi funrara wa, a jẹ ẹni-opin. Oun jẹ ailopin. Ati awa jẹ ẹni opin.... A si le ranti nitori wipe a kò tobi tó, ṣugbọn Oun jẹ ẹni nla, ti o fi jẹ wipe O gbagbe pe a ti dẹṣẹ ri. A jẹ ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun niwaju Rẹ̀. Ati ohun gbogbo ti O jẹ, Ohun naa ni a jẹ́. O di ẹ̀ṣẹ̀ mi, ki emi le e di ododo Rẹ. Nitorina, Ọlọrun kò le e ri ẹṣẹ kankan ninu rẹ ni wọn igbati ijẹwọ rẹ ba wa ninu Kristi Jesu.

37 Ẹnikan sọ wipe, ni igba kan .... O wipe, “Ti emi ba gba irú nkan bayi gbọ́, emi yoo ṣe ohun to wu mi! emi yo ṣe oriṣiriṣi iwa-ibajẹ. Emi yoo lọ si gbọngan ile ijo… Emi yoo mu ọti yó to bẹẹ gẹ́, ati ohun gbogbo, nitori wipe . . .

“Kini idi?”

A ti fi mi pamọ sinu Kristi. Iyatọ kini o jẹ́?“

Mo wipe, “Eleyi fi han pe iwọ ko ti ri i gba.” Ti ifẹ Ọlọrun ba wọ ọkan rẹ, ninu iwa tutu ti Jesu Kristi, iwọ yoo wà ninu ifẹ pẹlu Rẹ, ayé yoo jẹ òkú gẹgẹ bi ẹ̀ṣẹ̀ rẹ. Bayi ni iwọ yoo ṣe mọ pe iwọ ti ni Ẹmi Mimọ. Ko ki n ṣe pe nitoripe o le kigbe, pariwo, sọrọ pẹlu ede ajeji, tabi ohunkohun ti o le jẹ́, ṣugbọn nigbati ẹ̀ṣẹ bá di òkú ti o ba si wa laaye ninu Jesu Kristi. Ah, ifẹ Ọlọrun, bi o ti dara to, bi o ti jẹ mimọ to! Ṣe ẹ ri? 45:16

38 Nisisiyi, ni ilu Louisville Kentucky nibiyi, ni aipẹ, ojiṣẹ-Ọlọrun kan n sọrọ pe omidan-binrin kekere kan wa. O pẹ diẹ ki o to ṣe igbeyawo, ni bi i ọmọ ọgbọn ọdun. O si jẹ ọmọbinrin ti o dara, ti o jẹ ojulowo ọmọbinrin onigbagbọ. Ọmọkunrin kan si wa ni ilu Louisville ti kò .... kò ti gbe irú igbesi-aye ti o dara bi eleyi. O ti lọ si ile ijo ati awọn ile-ìbàjẹ́ ti o wa ni ẹgbẹ ọna ati oriṣiriṣi bi eleyi, ṣugbọn ni ọjọ kan o ri idariji fun ẹṣẹ rẹ, o si di Kristẹni tooto, ojulowo Kristẹni tootọ. Lẹhin ọdun kan si igba naa, o nifẹ si omidan-birin yi, omidan-birin yi si nifẹ rẹ gidigidi. Wọn si jọ ṣe igbeyawo.

39 Lẹhin igba ti wọn jọ n gbe papọ ni bi i ọdun meji, wọn sọ wipe omidan-binrin yi sọ fun ọkọ rẹ ni ọjọ kan .... o wipe, “Ololufẹ, o dabi ẹnipe o nira fun ọ, o ṣẹṣẹ di Kristẹni tuntun ni,” o wipe, “Mo ti jẹ kristẹni lati ọdọmọbinrin kekere.” Ṣugbọn o wipe, “Fun iwọ, Kristẹni tuntun, o ni lati dojukọ awọn iṣoro ati idanwo ti o maa n ba nkan wọnyi rin lẹyin igba ti eniyan ba ti wa ninu ẹṣẹ fun igba pipẹ.”

O si sọ wipe, “Lootọ, ijakadi ni.”

O wipe, “Mo fẹ ki o ranti, ohun kan, pe ti ọ̀tá bạ se ohun kan si ọ lati da ọ ni agara ni ibikan, ti o ba si ṣubú, ti o ba si pada sinu ẹ̀ṣẹ, maṣe sa kuro ni ilé. Mo fẹ ki o pada si ilé.” O wipe, “Iwọ yoo ba iyawo rẹ kanna ti o fẹ ni ile.” O wipe, “Emi yoo ràn ọ lọwọ lati gbadura pada, n o si gbadura fun ọ, titi ti iwọ yoo fi pada si ọ̀dọ̀ Ọlọrun lẹẹkan si.” O wipe, “n ko fẹ ki o salọ.” O sọ pe, “wo o, mo fẹ ọ nitori wipe mo nifẹ rẹ, kii ṣe nitori ohun ti o ti jẹ tẹlẹ.” O si sọ wipe, “Laibikita ohunkohun ti o ba ṣe, mo ṣi ni ìfẹ́ rẹ sibẹ. Mo fẹ ọ nitori wipe

mo nifẹ rẹ.”

40 Ati ọkunrin naa ni ojọ naa lọ si ibi-iṣẹ, a si gbọ pe o n tún eleyi sọ ni ibi .... ni ibiti o ti ń ṣiṣẹ. O wipe, “Nisisiyi, bawo ni ọkunrin kan yoo ṣe ṣe ohunkohun ti o kuna si irú nkan bi eleyi?” Nigbati obinrin kan, ti o ni ifẹ rẹ pupọ to bẹẹ gẹ ti o fi jẹ wipe ko si ohunkohun to wù ki o ṣe, o ṣetan lati pada, yoo si gba ọ pada, ki o si tun gbiyanju lẹẹkan si .... ṣe ẹ ri? O fi hàn pe .... Bayi, ṣe ìṣirò eleyi pẹlu ònka lọ́na bílíonu, nigbanaa iwọ yoo ni oye ohun ti ifẹ Ọlọrun jẹ́.

Pe nigbati eniyan ba wa ninu ifẹ pẹlu Jesu Kristi, awọn ohun ayé .... nigbati o ba ronu ohun ti o ṣe fun ọ ti a tọka rẹ ninu Iwe-Mimọ, kii n ṣe pẹlu nipa awọn isọyigi ara, ṣugbọn pẹlu okodoro otitọ, ohun ti o jẹ́, lẹhin naa ohun kan yoo ṣẹlẹ ninu rẹ nigbati ìbí tuntun ba dé .... ẹṣẹ ti di ikú si ọ bi ọganjọ oru. Nigbati .... Niwọn igbati ina yi i ba wa ninu rẹ, bawo ni òkùnkùn yoo ṣe tan? Ohun ko le e ṣe. Ohun ti Ọlọrun ṣe fun ọkunrin kan niyi ti o duro laarin alafo, ti o le e di ileri naa mú. Mose ti o si jẹ apẹẹrẹ ti ìdà-keji yi, idi niyi ti Mose fi duro laarin alafo fun awọn eniyan naa.

41 Lẹhin naa mo ro, ni ọjọ ti oni, ti iran Laodekia ti a n gbe ninu rẹ ti wọn ko ni ikora-ẹni-ni-ijanu, ti wọn ya ọ̀lẹ, ti wọn ko ni agbara. Gbogbo wa ni a mọ, ti a si ti kẹkọ nipa awọn igba ijọ, pe a n gbe ni igba ijọ ti o gbẹyin, igba ijọ ti Laodekia. Iran ti o ya ọ̀lẹ, ti wọn ko lee ko ara wọn-ni-ijanu, ti wọn n ta tẹ́tẹ́, ti wọn n sẹ̀fẹ̀, iran ẹ̀sẹ̀ ti o ni ifẹkufẹ ninu ti a n gbé ninu rẹ nisisiyi, o jẹ ohun iyanu pe Ọlọrun ko kan sọ wipe, “Ya kuro ninu rẹ. ijọ, Emi yoo pa gbogbo ẹgbẹ́ naa run.” Ṣe ẹ ri i? Iru iran wo ni a n gbe ninu rẹ yí. Oun yoo si ṣe eyi ni ọjọ kan ninu awọn ọjọ wọnyi, pẹ̀lú. A mọ wipe ọjọ yi n bọ wa, a ko ni fo eleyi, nitoripe, O ti ṣetan….. Ẹnikan ku fun awọn ti o fẹ ọna abayọ. Sugbọn yoo mu awọn ti o fẹ ….. tabi awọn ti o gba Kristi, ti wọn si ti di Kristẹni. A o mu wọn kuro ninu iparun, nitoripe nigba naa oun ko ni le e ṣe. Ko si ọna ti o fi le e ṣe e ni igba Mose.

42 Bayi ninu iwe ifihan, nigbati a de igba ijọ Laodekea …. Ninu Iwe ifihan ori kẹta, Bibeli sọ wipe igba ijọ yi, igba ijọ Laodekia jẹ afọju. O wipe, “Nitori wipe o jẹ ọlọrọ, o sọ wipe emi ni ọ̀rọ̀, emi si n pọ si ni ọrọ̀….” (Awọn ijọ ti o dara julọ, awọn eniyan ti o wọ aṣọ ti o dara julọ, eyiti o dara julọ ninu gbogbo igba iran ti o wa) “Nitoripe o sọ wipe, emi ko si ṣe alaini ohunkohun.' Ti iwọ ko si mọ pe talaka ni iwọ, ati àre, ati oṣi ati ẹni-ihoho, ati afọju, ti iwọ ko si mọ.

Bayi, ti eniyan ba wa ninu ipo yi, ti iwọ ba si sọ ipo rẹ fun un, oun yoo gbiyanju lati ran ara rẹ lọwọ ti o ba jẹ ẹniti ori rẹ pe. Sugbọn nigbati o ba wa ninu ipo yi ti o ko ba le sọ ohunkohun ti o yatọ fun un……. Ti oun ko si gbagbọ pe oun wa ni ihoho. Oun ko gbagbọ pe oun wa ni ipo yi, lẹyin naa eleyi fi han pe o jẹ afọju. Ọlọrun aye yi ti fọ oju awọn ti wọn kọ lati sin Kristi, wọn si ti…. Wọn ti fọju to bẹ ẹ gẹ ti o fi jẹ wipe wọn ko le ri ami igba ti a n gbe ninu rẹ, wakati yi, akoko ti a n gbe ninu rẹ. Si ranti pe, ẹnikan ti wa ti o duro ni aarin alafo, ko si si ẹlomiran ti o le e duro. O ni lati gba ọna abayọ yi tabi ki o ṣegbe.

43 Bayi fun awa, lati sunmọ ohun ti emi fẹ sọ. Ṣe a le duro….? (Bayi, emi nwaasu si ara mi, ninu eyi) Ṣe a le duro ki a si ri eniyan kan ti oju rẹ ti fọ, ti a si mọ wipe o n rin lọ lori etí apata……? Ṣe awa ninu ọkan pipe wa, ti a wa ninu rẹ yi ni owurọ yi…..? Ṣe awa le duro ki a si ri ọkunrin ti oju rẹ ti fọ, ti o n rin lọ sinu ọ̀gbun kan, ti oju rẹ si ti fọ, ki a maa si ṣe gbiyanju lati ṣe ikilọ fun un? Yoo jẹ ……. Yoo jẹ ohun ti o buru. A le jẹ ẹniti ko bikita ninu ọkan wa. Ṣe ẹ le fi inu gbe eleyi ro, ẹnikan ti ko bikita ti yoo fi jẹ wipe yoo fẹrẹ maa rẹrin, ti o si ri ọkunrin afọju kan (ẹniti ko le riran ti ko si le ran ara rẹ lọwọ) ti yoo si finu-fidọ rin lọ lori sinu ọ̀gbun? Eleyi yoo jẹ ohun to buru…… ti o ko si ṣe ohunkohun nipa rẹ.

44 O dara, si awọn arakunrin mi, ni gbogbo agbaye, mo fẹ ṣe ijẹwọ yi. Mo sọ eleyi pẹlu irẹlẹ, pe eleyi jẹ nipa ohun ti mo n ṣe, tabi ohun ti mo ń gbiyanju lati ṣe. Mo ti ń waasu fun igba pipẹ, mo si ti di arugbo ati agba oniwaasu ti o ni iriri. Mo si ti ni awọn ogun ti o ni agbara ati emi…. Boya…… Mo ti ni àpá, a ti gé mi ninu lati ibi awọn ija-ogun. Nitoripe ipin mi, ti Oluwa fi fun mi, kii n ṣe pe ki n fi ẹnu ko awọn ọmọ-ọwọ́ lẹnu, ki n si ṣe igbeyawo fun awọn ọ̀dọ́, ki n si ṣe isinku fun arugbo. Sugbọn o jẹ wipe ki emi mu ida - oloju meji niwaju ogun ki n si koju ija si ogun awọn abọrisa, ati ẹkọ - emi - eṣu, ati agbara okunkun, ki n si ba eyi ja pẹlu ọrọ Ọlọrun titi ti emi yoo fi ri pe aṣẹgun ọta. Ati ge mi wọnu ni ọpọlọpọ igba.

45 Lẹhin naa nigbati mo ba iṣẹ-iwaasu ti ọjọ oni yi pade, ti mo si ti sọ fun ijọ awọn ohun ti mo fẹ gbiyanju lati sọ. Ti mo si ti sọtẹlẹ ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin nigbati Ẹmi Mimọ pe mi si iṣẹ yi. Ko si ẹnikẹni ti o n gbe ni ori-ilẹ aye yi loni, ti o le sọ wipe Oluwa gba mi laaye lati sọ ohunkohun fun un ni orukọ Oluwa, sugbọn ohun ti yoo wa si imuṣẹ gẹlẹ ni ọna ti a sọ pe a o fi ṣe ẹ.

Bi o ti se kọkọ ran mi jade ati ẹbun akọkọ, ati ẹbun ekeji….. Ati ohun ti a sọ tabi ti a ṣe, ni gbogbo agbaye, o si fẹrẹ jẹ wipe ẹgbẹgbẹrun lọna milioni ti wa si ọdọ Kristi. Ati ẹgbẹrun lọna mẹwa ati lọna mẹwa awọn oniwaasu ni a ti mi si, ti wọn bẹrẹ isọji ti o gba gbogbo agbaye loni. Ati bi o ti jẹ wipe awọn ara Ijọ Afede-ajeji-ṣẹri Ẹmi Mimọ ni o gba iṣẹ iranṣẹ mi, awọn ni o fẹsẹ rinlẹ. Ijọ Afede-ajeji-ṣẹri Ẹmi Mimọ fi iyipada ọkan pupọ han ju …. Ẹgbẹ kekere ti, Ijọ Afede-ajeji-ṣẹri Ẹmi Mimọ, ju gbogbo awọn ijọ ti o ṣẹku lapapọ. Iṣiro rẹ niyi. Kini idi? Nitoripe wọn gba otitọ, wọn si gba isọji naa.

46 Ati nisisiyi, lẹhin igba ti a ṣe iwosan fun awọn alaisan, lile awọn ẹmi eṣu jade, ati jiji awọn oku dide, eyiti gbogbo wa jẹ ẹlẹri rẹ, ati ọpọlọpọ awọn dokita, ati awọn eniyan nla ti aye yi……. Ati ifarahan Jesu Oluwa laarin wa pe…… ninu ami nibẹ gẹgẹ bi ẹ ti ṣe ri, mo ro wipe lara ogiri tabi ibikibi ti o ba wa, niti angeli Oluwa, ati bi awọn onimọ ijinlẹ Sayẹnsi ti ṣe fi ontẹ lu akọsilẹ rẹ. O si jẹ otitọ ti a mọ, ni gbogbo agbaye. Ti a si ri ohun ti o ṣe ni pàtó, ti o si n wa si imuṣẹ nigba gbogbo. Lẹhin naa, ti ọwọn ina ti o lọ pẹlu Israeli ninu aginju ni igba Mose, ti awa……. Tabi nisisiyi ti a pe Mose ni, "Ojiṣẹ Oluwa" O si tẹlẹ ọ̀wọ́n ina ni oru, ati ikuuku ni ọsan.

47 Nigbati Jesu si wa ni ori-ilẹ aye, o wipe Oun ni Ọlọrun. O wipe, "Ṣaaju ki Abrahamu to wa, "EMI NI." EMI NI si ni ọwọn ina ti o wa ninu igbẹ ti o n jo ti o ba Mose sọrọ ni awọn ọjọ ti o kọja. Mo ro pe eyi jẹ otitọ, Arakunrin Vayle. Lẹhin naa O sọ wipe, "Mo wa lati ọdọ Ọlọrun Emi yoo si pada lọ sọdọ Ọlọrun." Ati nigbati a kan An mọ agbelebu…… ti O ku, ti O si ji dide, ti O si goke lọ si ọrun, ti O si fi ara Rẹ lelẹ si ori pẹpẹ nla ayeraye ti Ọlọrun. Lati wa nibẹ, ki O le wà laelae, lati le duro ni ipo wa, lati mọ pe O ti san gbese ẹṣẹ wa. Ati nibẹ ni O ti pada wa si aye lẹẹkan si gẹgẹ bi ọwọn ina nla naa.

48 Paulu mimọ, ni oju ọna rẹ….. ṣaaju ki a to pe e ni Paulu mimọ, a n pe e ni Saulu ti Tarsu. Ni oju ọna rẹ si Damasku, lati lọ mu awọn eniyan kan ti wọn n pariwo, ti wọn si n kigbe, ti wọn si n waasu Ihinrere ti o ṣe lodi si aṣa ti awọn ijọ…… ni oju ọna rẹ, ni ọjọ kan, ni bi i agogo yi ni ọsan ọjọ kan, a lu u bolẹ pẹlu ina nla kan. Ati ina nla yi….. Ati oun ti o jẹ ọmọ Juu mọ wipe ọwọn ina ni o dari awọn ọmọ Israeli, Oun si ni o wa niwaju oun yi lẹẹkan si, o kigbe wipe, "Oluwa!"

Bayi, ti o ba sakiyesi ninu ẹda kikọ Bibeli lapapọ ti Ọba Jakọbu, ati ti ẹda oṣuwọn ti a fi ontẹ lu ati oriṣiriṣi ẹda ti Bibeli, a fi alfabẹti nla kọ O-l-u-w-a Oun ni Elohim, Ẹniti O to ninu ohun gbogbo ti O da Ọrun ati aye, ninu iwe Gẹnẹsisi ori kinni ẹsẹ kinni. Oluwa! Bayi, Paulu ko le e pe awọn ojiji kan ni… ko le pe awọn - nkan ti ko mọ ohunkohun nipa rẹ, nitoripe o jẹ ọkunrin ti o ti kẹkọ ninu Iwe-mimọ. A si kọ ọ labẹ Gamaliẹli, olukọni nla ti ọjọ naa, oun ko si ni pe ohun naa ni Oluwa, ti ko ba ni idaniloju wipe Jehovah ni o jẹ. O wipe "Oluwa, tani Ọ?"

49 Ẹ tẹti si ohun ti O da a lohun, "Emi ni Jesu, ọkan naa lana, loni ati titi lae"

Nitorina, mo ro, ni aarin gbogbo rẹ ṣaaju ki a to tẹsiwaju, ni ibiyi ati ni gbogbo agbaye lapapọ……. Awọn eniyan ti wọn yoo ma a gbọ, ohùn yi lọwọlọwọ, yoo mọ pe a ti fi idi eyi mulẹ ni gbogbo ọna pe Jesu Kristi, O jẹ bakan naa ni ana, oni ati titi laelae. O ṣe ohun kanna ti O ṣe: O wo awọn alaisan san, O mọ ero ọkan wọn, O fi awọn ohun ti yoo wa si imuṣẹ han; yoo si wa si imuṣẹ ni pipe ni gbogbo igba ni gbogbo awọn ọdun ti o ti kọja lọ. Mo ti di ọmọ-ọdun mẹrin-le-ni-aadọta, mo si ti bẹrẹ si ni ri iran lati ọmọ oṣu meji-din-logun, ko si si akoko kankan…… sugbọn ni gbogbo igba ni o ma a n jẹ otitọ. Bayi, eleyi ni lati jẹ Ọlọrun. Ati lẹyin naa, emi n ronu pe, "Kinni idi ti awọn eniyan fi fọju to bẹẹ gẹ ti wọn ko fi ri eleyi?"

50 Ati ni gbogbo igba ti mo bá ba awọn obinrin wa sọrọ nipa gige irun wọn, ti awọn ojiṣẹ Ọlọrun si n ba mi ja nitori rẹ, ati awọn obinrin ti wọn n wọ awọn aṣọ ibajẹ, awọn ṣokoto penpe, ti wọn si duro bi eleyi nita, ti wọn si n tẹsiwaju ni ọna ibajẹ wọn ati nipa awọn ọkunrin wa bi wọn ti ṣe n huwa, ti wọn n fa siga, ti wọn si n mu ọti gbajumọ ati ohun gbogbo, ati sibẹ ti wọn n pe ara wọn ni Kristẹni, ti wọn si n gba ara Oluwa ni ori tabili nitoripe wọn jẹ ará ẹgbẹ́ kan ti a fi ọgbọn eniyan gbé kalẹ. Oo, o kan jẹ……. Wọn ro wipe mo ti sọrọ odi si Ọlọrun ni. Njẹ ṣe awọn obinrin huwa ti o dara siwaju si? Wọn tubọ n buru siwaju si, ni gbogbo orilẹ-ede.

Lẹyin naa emi, bi o ti jẹ wipe ara mi ko balẹ…….. (Mo sọ eleyi pẹlu ohùn irẹlẹ boya irú ẹniti ọpọlọ rẹ ko pe daadaa ti emi jẹ) ti emi si mọ wipe emi ko kun oju oṣuwọn fun iṣẹ naa, ati awọn oriṣiriṣi eniyan ti wọn ti ṣaroye nipa rẹ, ti o ni ohun lati ṣe, o nira. Sugbọn mo ro, "Ọlọrun, ki ni idi ti Iwọ ko fi pe ẹnikan ti yoo le e ṣe ẹ. Mo si tọrọ gafara, sugbọn mo ti kuna. Awọn eniyan ko ni fẹ gbọ ohùn mi. Mo ti kuna lati ṣe ohun ti o yẹ ki emi ṣe, ni ibikan, nitoripe wọn ko ni tẹtisilẹ lati gbọ ohun mi"

51 Iya mi ti o ṣẹṣẹ kọja lọ sinu ogo (o ti fẹrẹ kọja ọdun kan bayi)……. Iya mi…… Baba rẹ jẹ ọdẹ. Mo si ro, mo fi gbogbo eleyi jọ ọ nipa ọdẹ siṣẹ, nitoripe mo nifẹ aginju. Mo si ro, "Ti awọn eniyan wọnyi ti wọn pe ara wọn ni kristẹni, ti wọn ko ba fẹ gbọ iwaasu ti mo n waasu, lẹyin naa ẹ jẹ ki emi fi wọn silẹ. Emi yoo kan danu-duro lori gbogbo rẹ, emi yoo si lọ si ori-oke. Mo si mọ ọrẹ kan nibiti ….." Ọpọlọpọ ninu yin, nibiyi, ni yoo ranti nigbati mo sọ nipa akòko, ni bi i oṣu mẹfa ṣaaju ki eleyi to ṣẹlẹ, bi o ti jẹ wipe emi yoo lọ si ibikan, (lati ibi aga iwaasu yi): ẹranko kan yoo si wa ti yoo farajọ agbọnrin pẹlu awọn ìho ti o yọ siwaju bi o ti jẹ wipe ìho yi yoo gun ni iwọn inṣi meji-le-logoji, ati bi ẹranko miran yoo ṣe jẹ iwọn ẹsẹ bata meje ti o ni àwọ̀ eeru ni ibi tente ìho naa. Eleyi wa ninu ohùn ti a gba silẹ ati ohun gbogbo. Emi yoo gba a….. Ṣe ẹ ranti akoko naa; gbogbo yin. O dara, o wa ninu iyara mi bayi lati fi han pe o jẹ otitọ.

52 Bayi, lori awọn ohun bi eleyi nitoripe o jẹ ṣaaju ki iya mi ki o to kọja lọ, O si n duro pe ki O tu mi ninu nitori ohun ojiji nla naa ti o fẹ ṣẹlẹ, pe ….. O mọ wipe Oun fẹ mu u lọ.

Bayi, mo pade ọkunrin kan……. O jẹ Kristẹni, o si ni orilẹ-ede nla kan labẹ ilu Alaska. Mo si ṣe ipinnu ninu ọkan mi, nitoripe mo ti fi ibiyi silẹ mo si ti lọ si apa iwọ-oorun, pe emi yoo mu iyawo mi, emi yoo si fi ọgbọn mu u wọ nu ohun kan. Emi yoo mu u lọ sibẹ, emi yoo si di afinimọ̀nà kan. Ati lẹyin naa, ti Oluwa ba fẹ ki emi ki o ṣe ohunkan….. Emi yoo jẹ ki irun mi gun soke emi yoo si…… irungbọn mi. Emi yoo si pada lọ sibẹ, n o si di afinimọna. Awọn ara ilu Indan meji tabi mẹta ni o n gbe ni ilu yẹn. Emi yoo kan di afinimọna, emi yoo si jẹ iranlọwọ fun ọgbẹni Bud. Ti Oluwa ba si fẹ ki emi ṣe ohun kan lẹyin naa emi yoo sọ wipe, “O dara, Oluwa” Oun yoo fun mi ni iran. Emi yoo si yọkẹlẹ jade sita.

53 Mo sọ fun awọn eniyan naa….. Emi ko ka ara mi si ohunkohun…… Awọn eniyan mọ eyi…….. sugbọn awọn eniyan ti sọ wipe, Arakunrin Branham, Oluwa ti pe ọ lati jẹ Wolii Rẹ, o dara, emi ko pe ara mi ni eyi, sugbọn mo ti bẹrẹ si ni de akoko ti emi ti mura silẹ lati ṣe e: lati ronu, “O dara, boya bẹẹ ni emi jẹ. Ti emi ba ri bẹ ẹ, o yẹ ki emi maa gbe ninu aginju. Ti emi ba si n gbe ninu aginju, lẹyin naa emi yoo jẹ wolii Rẹ.” Ṣe ẹ ri? “Lẹyin naa ti O ba si fẹ ran mi lọ si ibikan……. Nigbati ko ba ti ṣetan lati lo mi lẹyin naa daju daju emi yoo mu àwọ̀n-ẹja kan, emi yoo si ṣe awọn ohun kan” Bi-o-tilẹ-jẹ-wipe eleyi jẹ iwa imọtara-ẹni-nikan (Ṣe ẹ ri?) nitoripe mo fẹ ṣe eleyi. Nisisiyi, eleyi kii nṣe ohun ti…… mo fẹ ṣe. Ati nisisiyi, mo ti pinu eleyi ninu ọkan mi pe emi yoo ṣe eleyi.

Ati nisisiyi, ṣaaju ki a to waasu awọn igba ijọ meje, gẹgẹ bi a ti ya aworan wọn nibẹ…… ọpọlọpọ lo wa, loni, ti wọn wa nibiyi ni akoko yẹn ti wọn si mọ bi Oluwa ti bukun fun eyi, ni ara ogiri ni ẹyin lọhun ti a fi eleyi han, nkan….. Awọn melo ni o wa nibiyi, ti wọn wa nibẹ, nigba naa, nigbati o wa ni ọjọ naa?

54 Lẹyin naa mo ranti, nigba naa, ti arakunrin Jackson. O wa pẹlu wa nigba gbogbo. Arakunrin Junior Jackson, ara ijọ Mẹthodisi…. O jẹ oniwaasu ijọ Methọdisti kan. Bẹni, o joko nibiyi nisisiyi. Bayi, o tọ̀ mi wa pẹlu ala kan ati awọn arakunrin miran wá pẹlu iru awọn ala kanna. Nisisiyi, Oluwa dara si mi pupọ ati pe emi ko…. (emi yoo mu yin wa si iranti ni owurọ yi) Ṣe mo ti sọ itumọ ala ti o kuna fun yin ri?. Rara, sa! Nitoripe, pe Oluwa…. Emi ko ni sọ ọ sita ayafi ti emi ba tun ala yi ri, ti mo si mọ ohun ti o jẹ…. Ohun ti O sọ nipa rẹ, lẹyin naa emi yoo sọ fun ọ. Ati lẹyin naa, o wipe, mo ni isin ninu ile-ijọsin rẹ, lọna kan tabi omiran….. o ni aibalẹ ara pupọ ni alẹ ọjọ naa. O si sare jade kuro ninu ile-ijọsin, o si ba ẹnu-ọna miran jade o si pade mi ninu ọkọ ayọkẹlẹ, awọn eniyan n kọja. O sọ wipe, “Mo fẹ sọ ohun kan fun ọ”

55 O si sọ fun mi pe oun lá ala kan, pe ni ibi apa oke ti o dabi ilu Indiana, pe oke kan wà ti o gun ti o si tobi ti o si ni koriko lori omi si ti fọ gbogbo iyẹpẹ ori rẹ kuro. O si ti di apata ti o dabi ẹnipe oke-tente ori apata ti o n dan. Ati lẹyin naa ni ara apata yi, ni a kọ ohun kan si ti o pani-lẹrin. O si wipe mo duro sibẹ pẹlu gbogbo awọn arakunrin, ni gbogbo awọn ilé-ijọsin nibiyi, ti mo si n sọ itumọ awọn ohun ti a kọ yi. Ati lẹyin igba ti o to akoko ti mo ti sọ gbogbo itumọ awọn ohun ti a kọ yi, lẹyin naa….. pe ni ọna kan tabi omiran, ti mo ba loye ala naa daada, mo mu ohun kan dani bi doje tabi ohun kan….. ti a fi maa n ṣi nkan tabi ohun kan…… tabi kii ṣe ohun kan ti o ni igun, ohun ti mo n ṣe apejuwe rẹ ni ohun ti o dabi doje ti a fi maa n ṣi nkan tabi iru ohun bayi, ti o kan gé ori sọnsọ oke naa kuro ti o si gbe soke. Ati ninu ori oke ti a ge kuro ni apata funfun kan wa, o dabi iru okuta gráníṫì tabi iru ohun kan bi eleyi, apata funfun kan ti a ko kọ ohunkohun si i rara. Mo si sọ fun awọn arakunrin pe, “Ẹ duro sibiyi ki ẹ si maa wo eleyi ati Emi ….” Nigbati gbogbo wọn n wo eleyi mo si yọ́ kẹlẹ kuro ni aarin wọn, mo si bẹrẹ si ni lọ si apa iwọ oorun. Arakunrin Jackson si sọ wipe oun ri mi ti mo n lọ si ibi apa oke kan, ati si apa oke miran, mo si n kere sii, mo si n kere sii, mo si n lọ si apa iwọ oorun. Ṣe ẹ ranti eleyi.

56 O dara, itumọ eleyi, ni tootọ, a sọ ọ ninu ile-ijọsin yi ṣaaju ki o to wa si imuṣẹ….. pe akoko naa ti de bayi, mo gbagbọ, pe ifihan kikun naa lati igba aye Luther, Wesley ati Johanu Smith, Alexander Campbell, ati orișirișì oniwaasu ti wọn ti waasu nipa Bibeli…. Ati pe a ri ninu Bibeli pe, a si fi han pe iṣẹ-iranṣẹ angẹli keje yoo wà. Ati pe nigbati ohùn iṣẹ-iranṣẹ angẹli keje yi ba dun, gbogbo awọn ohun ijinlẹ Ọlọrun ni a o fi han. Ninu rẹ ni ijinlẹ awọn àrá meje wà.

Ati nisisiyi, ti eleyi ba si jẹ opin, igba ti a n gbe ninu rẹ yi, nibiti a ti ni idalare, isọdi-mimọ, iribọmi ti Ẹmi Mimọ, ti a si ti ni àmì, ati iṣẹ iyanu, ati orisirisi nkan… Ti awọn ẹbun si ti pada sinu ijọ. Gẹgẹ bi i iwosan lati oke wa, ati isọtẹlẹ ati fifi ede ajeji sọrọ, ati itumọ. Bi o tilẹ jẹ wipe a ti ṣi eyi loye, ni ọna ti o yani lẹnu…. Sugbọn sibẹ, eleyi ko mu u kuro, ojulowo ṣi wa. Eyiti o jẹ otitọ ṣi wa (eyiti o jẹ ojulowo tootọ) ẹbun ti fifi ede ajeji sọrọ eyiti o yẹ ki o wa ninu ijọ nigba gbogbo.

57 A ni ọpọlọpọ awọn alafarawe. A ni ọpọlọpọ awọn eniyan ti wọn yoo dide ti wọn yoo si gbiyanju lati huwa gẹgẹ bi Kristẹni, igbesi aye wọn kò si wa ni ibamu, nitori naa ohun kan ti kuna. Jesu sọ wipe, “Nipa eso wọn ni a o fi mọ wọn” Ṣe ẹ ri? Bayi ni a ṣe n mọ Kristẹni nipa bi o ti ṣe ń gbé igbesi aye rẹ. Nitorina maṣe bẹ soke ju igbesi aye ti o n gbé lọ. Nitorina iwọ kan…… sugbọn ninu ibẹ…. O jẹ eṣu ti o n ṣe kuku-laja lati le tan onigbagbọ tootọ, onigbagbọ ojulowo kuro ninu ohun ti o jẹ otitọ. Sugbọn ki Ọlọrun ran wa lọwọ lati le ṣe iyatọ ki a si le mọ eyiti o tọ́ yatọ si ohun ti ko tọ́. Nigbagbọgbo ni Ọrọ naa yoo mu ohun ti o tọ jade.

Nisisiyi, a ri ninu eleyi pe, mo sọ itumọ ori apata naa pe…. Ati pé apata naa jẹ Kristi ti o wa ninu ala arakunrin naa. Eleyi si jẹ Bibeli. Ati fun gbogbo awọn ọdun wọnyi, a ti ṣi Bibeli lóye titi o fi jẹ wipe a ti fun u ni itumọ atọwọ-dọwọ ti ẹ̀mí lati ìgbà yẹn……. A si fi ẹbun ti o kẹhin kun un ni igba ti Laodekia eyiti o jẹ akoko fun angẹli keje lati waasu ni igba Laodekia. Ni akoko naa, pe oriṣiriṣi awọn nkan ni yoo wà ti a ti ṣi loye ni gbogbo awọn igba ti o ti kọja.

58 Gẹgẹ bi Luther ti waasu idalare sugbọn o jẹ ki o fọ́nká nitori wipe ko pẹ pupọ ni aye. Ati lati ara iwaasu yi…. Lẹyin naa wọn da ijọ kan silẹ….. Luther ko da a silẹ rara…. Lẹyin Luther. Ati lẹyin naa. Wesley jade wa. Ati lẹyin Wesley, awọn ti o gba iwaasu Wesley gbọ́ da ijọ silẹ. Ati lẹyin naa ni Johanu Smith jade wa, awọn onitẹbọmi, ati lẹyin naa Alexander Campbell ati bẹbẹ lọ. Sugbọn awọn ọkunrin naa (awọn alatunṣe) wọn ko pẹ pupọ ni aye lati le tun gbogbo awọn nkan wọnyi ṣe. Ati nitorina ọpọlọpọ awọn nkan ti o jẹ otitọ ni a fi silẹ lai ṣe, gẹgẹ bi i. Ati lẹyin naa nigbati wọn ṣe eleyi….. Fun apẹẹrẹ, siṣe iribọmi eyiti Johannu Smith mu pada, siṣe iribọmi pẹlu ríri gbogbo ara-eniyan sinu omi, sugbọn pẹlu lilo àpèlé. Ati ọpọlọpọ oriṣiriṣi iru awọn nkan wọnyi ti a ko ṣe ni ọna ti o tọ ti a si fi wọn silẹ. Ati lẹyin naa o wa si opin, iwaasu iṣẹ-iranṣẹ ti o gbẹyin yẹ ki o mu gbogbo awọn nkan wọnyi tọ, ki o si mu gbogbo awọn nkan wọnyi si igbagbọ kansọsọ, Oluwa kan, iribọmi kan.

59 Ati nisisiyi, lẹyin igba ti a ba ti sọ itumọ Bibeli tan patapata, lẹyin naa ṣe akiyesi, yoo ṣi ade-ori apata ti o dabi ẹlẹnu-sọnṣo naa (kii n ṣe ikọni nipa ile olori ṣonṣo naa, bayi ko ki n ṣe eleyi nitoripe Emi….. Awọn eniyan ti wọn n kẹkọ nipa ẹkọ opomulero ile olori ṣonṣo….. Mo ro wipe wọn mọ ohun ti wọn n sọrọ nipa rẹ. Emi ko mọ ohunkohun nipa rẹ) Sugbọn ni ọnakọna, o ni irisi ti o dabi ile olori ṣonṣo naa. Sugbọn ade ori ti o wa ni ile olori ṣonṣo naa ni a ko fi de e ni ori. Nisisiyi, mo ti wa ni ilu Cairo ati ni ilu Egypti, ade-ori rẹ ko si nibẹ nitori wipe o jẹ igun ile - o jẹ ade-ori ile. Ninu ijọ, o jẹ igun ile. Ni ẹkun-rẹrẹ ijọ, O jẹ ade-ori ile. Nitorinaa ko si nibẹ. A ti kọ ọ silẹ. Kristi! Oun yoo si wa. Mo si gbagbọ pe nigbati O ba n bọwa, pe ijọ yoo wa ni ipo lati idalare ni abẹ Luther, isọdimimọ ni abẹ Wesley, ati iwaasu Pentikọsti yoo mu ijọ wa si ẹgbẹ́ kereje. Ati iṣẹ-iranṣẹ kan yoo wa ni aarin awọn eniyan wọnyi titi ti yoo fi jẹ iṣẹ-iranṣẹ kanna gẹlẹ bi i eyiti Jesu Kristi ṣe. Eleyi yoo mu Jesu wa yoo si mu gbogbo nkan yi lọ.

60 Awọn ti wọn jẹ eniyan oninu funfun ati olootọ ti ara ijọ Luther ara ijọ awọn Alagba, awọn ara ijọ onitẹbọmi awọn ara ijọ Mẹthọdisti, ati ẹnikẹni ti a bí lati ipasẹ Ẹmi Ọlọrun ni a o mu lọ pẹlu Jesu nigbati O ba de. Mo gba eleyi gbọ. Mo tako diẹ lara awọn arakunrin ti Ijọ Afede-ajeji-ṣẹri Ẹmi Mimọ wa ti wọn gbagbọ pe awọn perete ti o ku ninu ijọ ni awọn ti a o gba soke ni ìgbà ijọ ti o gbẹyin. Mo tako eleyi nibẹ yẹn nitoripe Ọlọrun…. Bawo ni ọkunrin kan…. Bawo ni Ọlọrun ….. ti a ba fẹ sọ eleyi “Bawo ni Oun?” Oun le ṣe ohun ti O wu U lati ṣe. Sugbọn Ọlọrun ti O ṣeleri fun Luther. Labẹ idalare, gbogbo ohun ti wọn mọ ni eleyi. Ṣe ẹ ri? O ṣeleri wipe Oun yoo mu ijọ. Ati pe Oun…… Mo gbagbọ nipasẹ oore-ọfẹ Ọlọrun ati nipasẹ Iwe Mimọ….. yoo jẹri gbe eleyi. Nitori wipe ko wa ni igba ìsọ́ akọkọ, wọn lọ sun ati ni igba ìsọ́ keje, O de. E yi si ni igba ijọ keje. Eyi si ni iwaasu iṣẹ-iranṣẹ angeli keje. Ṣe ẹ ri? Ati nigbati O ba de, gbogbo awọn wundia wọnyi yoo dide wọn yoo si tun atupa wọn ṣe. Awọn ara ijọ Alagba, ijọ Luther, ijọ onitẹbọmi, ẹnikẹni ti a bi lati ọwọ Ẹmi Ọlọrun ni yoo lọ si igbanilọsoke. Mo gbagbọ pe a o gba iyawo soke ni akoko yi. Mo gbagbọ wipe awọn kan yoo wa ni ọjọ ikẹyin yi ti wọn ko ni tọ iku wò sugbọn ti a o yi wọn pada ni iṣẹju kan, iṣẹju àáyá kan.

61 Nisisiyi ……. Sugbọn niwọn igbati ẹ ba ti ṣe akiyesi gẹgẹ bi ala Arakunrin Jackson, pe a ko kọ ohunkohun sinu apata ti o wa ninu oke naa, ìdí ti mo fi lọ si apa iwọ-oorun niyi. Bayi gẹgẹ bi o ti ṣe ṣẹlẹ ……. Mo si sọ fun yin. “Ni ọjọ kan emi yoo sọ itumọ ohun ti o jẹ fun yin” Mo lọ si apa iwọ-oorun nitori rẹ. Mo si sọ iran ti awọn eniyan, ti awọn ti wọn n gbọ ohùn iwaasu yi ati awọn ti wọn wa ni ibi yi ni owurọ yi, wọn yoo mọ igbati a waasu lori Ẹyin Alagba Akoko Wo Niyi? Ati eyikeyi awọn arakunrin ti wọn maa n gbọ awọn ohùn ti a gbà silẹ ti ẹ ko si ni iwaasu yi, ti ẹ si fẹ tẹle eleyi, ẹ mu iwaasu naa Ẹyin Alagba, Akoko Wo Niyi? Ṣaaju…… Ọpọlọpọ awọn ọsẹ ati awọn oṣu ṣaaju ki o to ṣẹlẹ nibiyi, mo ri iran pe mo wa ni ilu Tucson, apa ariwa ti ilu Tucson, eleyi yoo jẹ apa ila-oorun ti ilu Flagstaff, apa ariwa ti ilu Tucson, mo si bẹrẹ si ni mu èèmọ́ kuro lara ẹsẹ ṣokoto mi, ìró ariwo nla kan si dun ti o si dabi wipe……….. o mi orilẹ-ede naa. Melo ninu yin ni o ranti eleyi? Eyiti yoo mi orilẹ-ede.

62 O dara, o ṣẹlẹ wipe o kere tan ọkunrin kan wa nibiyi ni owurọ yi ti o wa ni duro ni ọjọ naa nigbati ohun yi ṣẹlẹ. O mi apata naa kuro ni ori-oke naa. A ri wipe ni akoko naa, mo ri awọn angẹli meje ni irisi Piramidi (ile-olori-ṣonṣo) ti o sọkalẹ wa ti o si gbe mi soke. A si mu mi lọ si apa ila-oorun lati le ṣi awọn edidi meje naa fun Ọlọrun. Ti iwọ ko ba ti ni i……. Ti Jesu ba fa bibọ rẹ sẹyin, ati emi….. awọn ọmọ-ọmọ-ọmọ mi, awọn ọmọ Paul kekere…… eleyi yoo maa jẹ otitọ ayeraye ti Ọlọrun Alaaye! Bayi, a o wadi eleyi….. ohun ti a fi edidi di ti o wa ninu oke yi. Eyiti a ko kọ silẹ. A ni lati sọ itumọ rẹ. Ati nigbati mo ba padawa, angẹli akọkọ, ni alẹ akọkọ, ṣi edidi naa yatọ si ohun ti a ti maa n gbọ tẹlẹ rí ni ọjọ aye wa. Ati gbogbo awọn angẹli meje yi ni o jade wa ni ọna kanna. Ẹ mọ eleyi. Ẹ wa nibiyi ni oju yin nigbati eleyi ṣẹlẹ, ọpọlọpọ ninu yin.

Ati nisisiyi, Emi ko mọ eleyi nigba naa sugbọn.

63 Arakunrin Fred Sothmann, emi mọ pe o wa nibiyi. O si dami loju diẹ wipe arakunrin Norman wa nibiyi. A wa ni oke……… mo ni lati lọ si ilu Houston lati le dóòlà ẹmi ọmọkunrin kekere naa kuro ninu aga ẹlẹtiriki. Ati lẹyin naa mo pada lọ, mo si lọ si ibi oke nibẹ lati lọ sọdẹ pẹlu awọn arakunrin. Ati ni owurọ naa, mo si duro nibẹ mo n yọ èèmọ́ kuro, tabi ohun ti wọn n pe ni “ẹgun bi i ori-ẹran” nibẹ; wọn wa ni gbogbo eti ṣokoto mi. Ariwo nla naa si dun gẹlẹ ni ọna ti mo sọ pe yoo ṣe waye. Ṣe eleyi jẹ otitọ, arakunrin Fred? Yoo si jẹ wipe a o ti gbe mi kuro lori ilẹ lọ si oke. Ati ni oke ori mi ni awọn angẹli Oluwa wa ti wọn fi ohùn ranṣẹ pada si mi pe, ki emi ki o wa si ibiyi lati le ṣi awọn edidi wọnyi. Kini idi ti o fi jẹ ibiyi? Kini idi ti o fi jẹ ile-ijọsin yi? Kini idi ti emi ko fi ṣe e ni ibẹ? Nitori wipe mo ti ṣe ileri fun ijọ mi ati si Ọlọrun pe gbogbo iwaasu ti o ba jẹ tuntun yoo jade wa lati inu agọ-ijọsin yi, a o si ṣe gbigba ohun iwaasu naa silẹ ni ibiyi. Ati pe O si ń ran mi lọwọ lati pa ọrọ mi mọ, lati le duro si ibiyi ki n si ṣe bẹ ẹ. Ati ni lọgan mo tun pada lọ sibẹ.

64 Ati nisisiyi, emi ko mọ akoko, ti wọn n ya awọn aworan nkan yi. Awọn onimọ ijinlẹ sayẹnsi lo ṣe e, bi awọn angẹli ti ṣe n sọkalẹ lati ọrun wa ti wọn si n mu iṣipaya iwaasu naa wa. Ẹ si ranti pe, mo sọ wipe eyiti o wa ni apa ọtun akojọpọ awọn angẹli naa o ni…… o dabi wipe o kọ iwaju aya rẹ sẹyin, ati awọn iyẹ rẹ….. ṣe ẹ ranti pe mo sọ eleyi, gbogbo yin? Ati bi mo si ti ṣe n wo o? O yatọ gédégbé laarin awọn iyoku. Emi ko si mọ pe wọ n ya aworan rẹ, nitori wipe ni kiakia ni mo yara lọ si apa ìwọ-oorun. Sugbọn nigbati emi n pada lọ si ilé si ilu Tucson, o wa ni gbogbo iwe-iroyin atigba-degba eyiti gbogbo agbaye ti fẹrẹ ri i tan tabi ti o wọ ilu Mexico, ati ni gbogbo awọn ipinlẹ ti o wa ni apa Iwọ-Oorun. Mo si ro wipe ile-iṣẹ ti o maa n fi ẹru ranṣẹ ni ibiyi……. O wa ni Agbarijọpọ ile-iṣẹ ti o n tẹ-iwe. Ẹni melo ni o ri ikuuku ti o yani-lẹnu ni oju-ọrun? Ṣe ẹ ri awọn ọwọ́ yẹn. Ati nisisiyi, ile-iwe iwe-iroyin atigba-degba ti a n pe n Life gbe eleyi jade. Mo si ni Arokọ - Akọsilẹ rẹ nibiyi ni owurọ yi. Ninu iwe Iroyin atigba-degba Life ti afihan naa…… Bayi, ohun niyi, ni akoko kannaa ti mo wa nibẹ. Ṣe ẹ ri ikuuku naa ti o dabi ile-olori ṣonṣo? Mo duro taara ni abẹ eyi. Ati nibẹ……. Ṣe ẹ ri angẹli naa ti o yatọ ni apa ọtun? Ṣe ẹ ri ìyẹ́ rẹ ti o yọgun sita? Ni ibamu pẹlu ohun ti a sọ gẹlẹ. Ati nibiyi a ṣe iforọ wanilẹnuwo lori rẹ ni ilu Mexico ati ni ọpọlọpọ ibi gbogbo lati ibiti wọn ti ya aworan rẹ. Nisisiyi, onimọ ijinlẹ sayẹnsi yi n gbiyanju lati gba gbogbo iroyin nipa aworan naa….. ati nipa awọn eniyan ti wọn ní aworan naa. O n sayẹwo finfin; nipa rẹ.

65 Bayi, o sọ nibiyi pe ko le e ṣe ẹ ṣe pe yoo jẹ ikuuku kan nitoripe afẹfẹ-omi ko ki n ga ju……. Mo sọ wipe bi i iwọn maili mẹfa tabi mẹjọ ni giga, bi eleyi. Nigbati a ba n rin irinajo lọ si òkè-òkun ọkọ baalu maa n gbe wa fo soke bi i iwọn ẹsẹ bata ẹgbẹrun lọna mọkan-din-logun, a ti kọja awọn iji nigba naa. Sugbọn ikuuku yi, gẹgẹ bi apilẹkọ ti awọn onimọ-ijinlẹ sayẹnsi ti o wa nibi, o jẹ iwọn mẹrin-din-lọgbọ maili ni giga. Ọpọlọpọ maili ni o wa kọja afẹfẹ-omi. O si sọ wipe, nigbati ẹ ba wo agbegbe yi….. Ati nisisiyi, ṣe ẹ mọ emi…… Ẹni melo ni o ranti pe mo ti sọ fun yin, o dun bi i igbati ọkọ baalu ba la ìró agbara kọja? Ṣe ẹ ranti? Sugbọn ko si ọkọ-baalu ni agbegbe nigba naa. Iwe ti a kọ sọ bẹ ẹ, nibiyi. Wọn yẹ ẹ wo. Ko si ọkọ - baalu kankan ni oju ofurufu nigba naa. Ati pe lẹyin naa, ko le……. Ikuuku ti o wa ni ẹyin ọkọ-baalu ko jẹ nkankan sugbọn o kan jẹ afẹfẹ ti o ti pin yẹlẹyẹlẹ afẹfẹ-omi. 'nitoripe o fi agbara gba ọna naa kọja, gẹgẹ bi i, ọkọ-baalu ayara-bi-asa. Bi o ti ṣe n fi agbara la ikuuku ti o wa ni oju-ọrun kọja. Ko le bori eleyi laelae niwọn igbati ọkọ-baalu ayara-bi-àṣá ba ṣi wa, nitoripe o yẹ ki o……… Nitoripe ori rẹ ni o ti n gba agbara lati gbera. O si jẹ afẹfẹ ikuuku ti o n fi agbara jade ni kiakia lati ibẹ.

66 Sugbọn ohun niyi, ọpọlọpọ maili ni o fi ga soke ju ibiti afẹfẹ ikuuku le wa lọ, ko si si ọkọ-baalu kankan ni agbegbe naa nigba naa. Ko si le e si afẹfẹ-omi kankan ni oke nibẹ, ti yoo si duro soke ni ọjọ naa. O jẹ iwọn ọgbọn maili ni ibu rẹ, o si jẹ iwọn mẹrin-din-logun maili ni giga rẹ. Ṣe, ẹ ri i? O ri gẹlẹ bakana, ohun ni aworan ti a gbekọ soke nibẹ yẹn, nigbati mo sọ fun yin, angẹli Oluwa naa dabi ọwọn ina ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin, ṣaaju ki a to ya aworan rẹ. Ọlọrun gba awọn onimọ ijinlẹ-sayẹnsi lati loye pe o jẹ otitọ. Bayi, nibo ni a wa? Mo fẹ fi eleyi pamọ, nitoripe o ṣeeṣe ki n sọ fun ọrẹ mi ti o wa ni joko ni owurọ yi ki o ba mi kọ awọn edidi meje wọnyi. O le fẹ eyi fun un. Nitori naa, ẹyin ti ẹ ni ẹda rẹ……. kini idi, ti o ba ni, ẹyọkan, mu u dani lati fi ṣe atọka. Ṣe ẹ ri?

67 Bayi, o fẹ ṣe iwadi, sugbọn anfani kini o jẹ nigbati o ba sọ eleyi fun un? Yoo fi ṣe awada ni. Ṣe ẹ ri, yoo kan rẹrin ni. Nitorina ẹ maṣe jẹ ki a sọ Pearli wa silẹ bi eleyi. Sugbọn a mọ, ijọ mọ, Ọlọrun si mọ pẹlu pe o jẹ otitọ.

Ati lẹyin naa nigbati mo n gbadura lori akori yi, ti mo si n finu gbero rẹ pe kini yo ṣẹlẹ simi, ẹ si mọ ibiti mo wa? Apa Ariwa ilu Tucson, apa ila-oorun ilu Flagstaff; ni gẹlẹ, ni ipo rẹ, ibiti mo ti sọ fun yin ni ọpọlọpọ oṣu ṣaaju ki o to ṣẹlẹ pe emi yoo duro. Ati ni pipe, gẹgẹ bi iwe akọsilẹ ti o wa nibiyi ati awọn iwe…… ati iwe - iroyin atigba-degba, ati ẹri wa pẹlu, ni ibiti o ti ṣẹlẹ gan. Ọlọrun jẹ pipe ko si le E ṣeke. Yoo si wa si imuṣẹ.

68 Ṣe ẹ ranti ninu ohùn ti a gba silẹ, Ẹyin ỌAlagba Akoko Wo Ni A Wa Yi? Mo tun ayọka rẹ sọ, “Ṣe ẹ ranti, pe ohun kan fẹ ṣẹlẹ - ohun pataki!” Nisisiyi, O jẹ ki gbogbo orilẹ-ede jẹri si eleyi. Gbogbo awọn iwe-iroyin kọọkan ti o wa ni agbarijọpọ ile-iṣẹ ti o n tẹ iwe, ati ọkan ninu iwe-iroyin atigba-degba wa ti o n lékè, ati ohun gbogbo miran n jẹri gbe ni ibi gbogbo sibẹ. Sugbọn iru awọn eniyan ti o ri oore-ọfẹ, eniyan ti o ni oore-ọfẹ ni Kristẹni, lati mọ wipe ni akoko dudu yi nigbati ko si ireti mọ gẹgẹ bi awọn onimọ ijinlẹ sayẹnsi ti ṣe sọ, ati ti

ado oloro n duro de wa. Ko si si ireti fun awọn ile-iṣẹ wa, wọn n korajọ papọ, wọn n fi imọ-sọkan pẹlu ami ẹranko naa. Ati lẹyin naa gbogbo ireti wa ni ipa ọna yi ti ṣegbe - ninu iṣẹ iṣowo wa, ninu idapọ ti kristẹni laarin awọn ile-iṣẹ ….. gbogbo rẹ ni o n korajọ - papọ si ẹ̀sìn ti ijọ Katoliki, eyiti yoo jẹ ami ẹranko naa ninu agbarijọpọ ti gbogbo ijọ.

Sugbọn si awọn ti o fẹran Ọlọrun ti wọn si n wa ojulowo pe Ọlọrun naa ti o ṣe ileri ninu Bibeli, o fi eleyi han gbangba niwaju wa o si jẹ ki ijọ, ati awọn eniyan, ati imọ ijinlẹ sayẹnsi, ati iwe-iroyin atigba-degba, ati ohun gbogbo ki o ni oye pe Oun si ni Ọlọrun O si le e sọ akoko. Iru akoko wo niyi!

69 Lẹyin naa ni Sabino Kayoni ni owurọ ọjọ naa, mo n gbadura, mo si n ronu pe kini ohun ti yoo ṣẹlẹ, mo gbe ọwọ mi soke si Ọlọrun ni tente ori-oke naa, ida naa bọ si ọwọ́ mi ……….. pẹlu ìdí pearli, pẹlu ikọ̀ rẹ ni ori rẹ, pẹlu abẹ ti o gun to iwọn ẹsẹ bata mẹta o si n dan bi i ikoko idẹ tabi ohun ti ori rẹ ri roboto, abẹ-fẹlẹ ti o mú; emi ko si mọ ohun ti o jẹ. Mo si sọ wipe, "Ẹru awọn nkan wọnyi ba mi"

Ati lẹyin naa ohun kan sọrọ ti o mi afonifoji ibi pẹtẹlẹ naa. O wipe, Eleyi ni Ida Oluwa." Ida Oluwa si jẹ 'Ọrọ Oluwa." Nitori Ọrọ Ọlọrun mu ju ida oloju-meji lọ.

70 Nigbati mo n pada bọ sinu eleyi……. Ni akoko naa arakunrin olootọ kekere kan ni ile ijọsin nibiyi, o si jẹ……. O jẹ jagunjagun, a si fẹrẹ, fi ibọn fọ ọ si wẹwẹ, nigbati o jẹ jagunjagun o wa ni oju-iku; o si sọ wipe, oun……. Wọn ko mọ……. Awọn oniṣegun ko mọ pe yoo ṣi wa laaye, ko si nilo pe ki a ṣe ohunkohun fun un, nitoripe o ti fẹrẹ ku. Iṣan ti o lagbara julọ ninu ẹsẹ rẹ ti fọ́, ati apa rẹ kekere ti fẹrẹ fọ danu patapata, ẹsẹ rẹ……… ọkan ninu rẹ ti fẹrẹ yọ danu, sugbọn Ọlọrun rí oore-ọfẹ, O gba a la, O si wo o san ni ọjọ kan. Arakunrin Roy Roberson, wa nibẹ nigbati a ya aworan naa ni ilu Houston. Bi a ti ṣe sọ fun iyawo rẹ lati ipasẹ iran; ohun ti o ti n ṣe ni gbogbo ọsan, ati bi o ti ṣe ni idaamu ati bi a o ti ṣe wo o san. Eleyi si jẹ ki o di onigbagbọ. Sugbọn o ti jẹ ọkunrin ologun pẹlu ohun kan (mo lero pe yoo dariji mi pe mo n sọ eleyi lati……..) …… o fi si apa ibi ti ko dan mọran, apa ibikan pàtó, ẹniti o ti n paṣẹ nibi iṣẹ-ologun. Gẹgẹ bi adari awọn eniyan, o ni lati kigbe-sita, "Ṣe e!" Ṣe ẹ ri? O si gbagbọ bi o tilẹ jẹ wipe. Sugbọn o si n tẹsiwaju diẹdiẹ pẹlu ijọ o si n ri ohun iyanu, o wipe, "Mo gba eleyi gbọ, sugbọn eleyi wa fun ẹlomiran."

71 Ni alẹ ọjọ kan Oluwa ji i dide, ni owurọ kan. A jọ duro, oun ati emi, o dabi wipe a wa ni ilu Jerusalemu ni ibi tabili ounjẹ alẹ Oluwa, mo si n sọrọ. Oye rẹ ko si ye. Arakunrin Roy, ti o wa nibẹ, o si n wo mi bayi; o si ri ohun yi. O si pe mi soke ni…….. ita ni ilu Arizona……. Tabi o fi iwe ransẹ si mi mo si tun pe e. O wipe, "O duro nibẹ, arakunrin Branham, mo si ri ọwọn ina nla naa wọle, O si gbe ọ lọ kuro ni ibi ounjẹ alẹ Oluwa naa, o si lọ si apa iwọ-oorun." Nitoripe o duro ni apa ila-oorun o si n wo mi bi mo ti ṣe n lọ si apa iwọ-oorun, imọlẹ yi si wọle, O si mu mi jade.

O wipe, o jẹ ni owurọ ọjọ kan, o dabi iran. O dide kuro ni ori-ibusun ni bi i dede agogo mẹta tabi mẹrin owurọ, bi iru eleyi, o si ri eleyi pe o ṣẹlẹ. O si wipe, oun kigbe o dabi pe fun ọpọlọpọ ọjọ́, "Arakunrin Bill, pada wa!" Roy ati Emi si ti jẹ arakunrin tootọ. A jọ n gbe papọ, a jọ ṣe ọdẹ papọ, a kan jẹ arakunrin. O si kigbe lati pe mi, titi ohun rẹ fi há ni ọfun rẹ. "Pada wa. Ẹ mu u pada wa. Ẹ mu u pada wa." - o n kigbe. O wipe, Emi…… Ọwọn ina niyi, O si tun n pada wa, tabi ikuuku pada wa, O si gbe mi si ori tabilii, a si ti yi mi pada. O jẹ ohun aditu fun arakunrin Roy; pe a yi mi pada si irisi to yatọ) - "pe a yi mi pada" - (Nigbati mo sọ itumọ rẹ fun un.)

72 Eleyi jẹ ṣaaju ki n to pada wa fun awọn edidi meje. Nigbati mo pada wa fun edidi meje lẹyin naa Emi….. Ni owurọ ọjọ kan, o sọ fun Billy pe oun fẹ ba mi sọrọ. Mo si ni ohun kan ti mo n ṣe, labẹ adura fun edidi meje, ati lẹyin o sọ fun mi nipa……. O tun ṣẹlẹ lẹẹkan si, o si tun ṣẹlẹ si. Arakunrin Roy, ti emi ko ba sọ eleyi daada iwọ pe akiyesi mi. O si wipe, o si tun dide ni owurọ. Mo ro pe ni owurọ kutukutu, nibẹ o ti wo iyara, o si ri imọlẹ nla yi, tabi ikuuku kan ni ori-oke kan. O beere ni ọwọ mi, ni aipẹ yi, "Ṣe ohun kan wa nipa pe ki ikuuku wa ni ibi ori-oke kan? Mo si sọ wipe….. "Ninu Bibeli"

Mo si sọ wipe, "Bẹẹ ni, nigbati a mu Peteru, Jakọbu ati Johanu tọ sori oke, ti ikuuku si bo Jesu Oluwa. Ti Ọlọrun si sọrọ ti O si sọ wipe, "Eyi ni Ayanfẹ Ọmọ Mi….." Mo waasu lori rẹ nibiyi, ni aipẹ yi. Iwaasu kekere kan, awọn ara ti wọn maa n gbọ ohùn ti a gba silẹ yoo ni oye eyi, Ẹ Maa Gbọ Ti Rẹ. O yẹ boya o wa ninu ohùn ti a gba silẹ. O damiloju.

73 O si sọ wipe oun lọ si ori-oke. Ati nigbati o ṣe eyi, mo duro nibẹ, ohun kan si jade wa lati inú ikuuku (Ṣe bẹẹ lori, Arakunrin Roy?) O si sọ wipe ohun ti o ri bi eleyi. "Eyi ni iranṣẹ Mi. Mo si ti pe e lati jẹ wolii fun Iran yi, lati dari awọn eniyan gẹgẹ bi Mose ṣe ṣe. A si ti fun un ni aṣẹ….. o le sọrọ pe ki ohun kan wa laaye." Iru ohun bi i eleyi…… gẹgẹ bi Mose ti ṣe, gẹgẹ bi i sisọrọ pe kii eṣinṣin ki o wa. A si mọ nipa ọkẹrẹ ati bẹẹbẹẹ lọ, ati awọn ohun ti o ti ṣẹlẹ. Hattie Wright kekere nibẹ, Mo ro pe e mọ ohun ti o ṣẹlẹ ni ile rẹ. O si sọ fun un wipe mo ti ṣe ohun ti Mose ṣe.

74 O si sọ eleyi fun mi nigbati mo de lati irin-ajo kan. Ati ninu ọkan mi, mo ti pinu ninu ọkan mi pe emi yoo lọ

si ọdọ ọgbẹni Bud, nitoripe o wa ni ipo ti o buru nibẹ, ọdẹ naa.

Ṣaaju ki n to kuro nibiyi o ṣeeṣe ki n ṣe eleyi. A o si yara. Mo la ala ti o panilẹrin kan, ala ti o ṣajeji kan. Mo si lero pe ti àna mi ba gbọ eleyi, ko ni ba a ninu jẹ. Mo ro pe ko ni ba iyawo mi ninu jẹ, ẹniti o wa nibiyi nisisiyi. Sugbọn o mọ eleyi. Ni bi i…… ọpọlọpọ oṣù ti o kọja, bi o ti ṣe n lọ…. O jẹ, ni bi i, ọsẹ kẹwa tabi ọsẹ kọkanla. Mo la ala pe mo n rin kiri ninu okunkun, ati emi……. Nigba naa, emi ko ni ile ti emi yoo lọ ko si si ẹnikẹni to bikita nipa mi. Mo si wa di alarinkiri, alarinkiri kan. Otutu si n mu mi, mo si wo iwaju mi, mo si ri ina. Nigbati mo si de ibẹ o jẹ ibiti awọn ara ilu naa n da idọti sí. Wọn si gbẹ awọn koto sibẹ, ina si wa ninu awọn koto yi. Ni aarin awọn koto yi ni alafo wa eyiti awọn alarinkiri yi yoo sùn si ki wọn le e pa ara wọn mọ kuro ninu otutu (ki wọn le pa ara wọn mọ kuro ninu otutu ti o ni agbara) ni aarin awọn ina wọnyi nigbati otutu ba mu ni igba aṣalẹ. Otutu si mu emi naa pẹlu. Mo si rin lọ si ibi ina yi lati le gbọn otutu ara mi danu, gbogbo awọn alarinkiri yi si pọ̀ nibẹ wọn si….. Emi ko ri ẹnikẹni ninu wọn, sugbọn o dabi ẹnipe wọn ni ibi ibuba tabi aye ibiti wọn maa n sun si. Mo si ri ana mi, ọgbẹni Fletcher Broy.

75 Ọgbẹni Fletcher, mo si ranti rẹ. O jẹ ọmọkunrin kekere ti o dara. Sugbọn eleyi le e jẹ ẹkọ fun awọn ọmọde. Mo ranti ni awọn ọdun diẹ sẹyin o jẹ ọdọmọkunrin to lẹwa, ti James Fletcher Broy, o si ba ẹgbẹ buburu rin, o si mu ọti rẹ akọkọ. Mo ranti pe o pe mi si ẹyin aṣọ-ilẹkun ni ile mi. Ati baba rẹ, ti o ti lọ sinu Ogo ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin, o wa nita ti o n kọrin pẹlu gita.

Lori oke giga ni igi agbelebu atijọ kan wa.

Flectcher si pe mi pada, o wipe, “Arakunrin Bill, gbadura fun mi. Tẹti-silẹ …… ohun elo-orin ti baba mi n tẹ yẹn, mo ti n mu ọti loni”

Mo wipe, “Fletcher….” (ni bi ọmọdun meji-din-logun) mo wipe, “Maṣe lọ si ipa ọna yẹn” Sugbọn ko gbọran rara. O tẹsiwaju o si di ọmuti pọnbele. Iyawo rẹ si kọ ọ silẹ, awọn ọmọ rẹ…… o si jẹ ni akoko yi……. Ọlọrun si mọ wipe mo fẹran rẹ.

Mo si lọ gbadura fun un, o jẹ alágbe. Mo lọ gbadura fun un, ni aipẹ yi, o ni ipalara, nigbati mo wa nibiyi pẹlu edidi meje. Mo si sọ wipe, “Fletch, mo ni awọn aṣọ suutu kan nibiyi ti mo nifẹ lati fi fun ọ.

O wipe, “Maṣe ṣe eleyi, Arakunrin Bill”

Mo si mọ pe ko ni aṣọ. Mo si sọ wipe, “kilode ti iwọ ko fi fẹ gba awọn aṣọ yi?”

O wipe, “Uh-uh” o si gboju soke wo mi, “Ṣe ẹ ri, ṣe o mọ ohun ti emi yoo ṣe pẹlu wọn. Emi yoo ṣe paṣiparọ wọn n o si mu ọti yo”

Mo si wipe, “Emi yoo fun ọ ni owo diẹ Fletch.”

O wipe, “Rara, maṣe ṣe bẹẹ arakunrin Bill. Emi ko fẹ ki o ṣe e” O jẹ ọkunrin olootọ ninu ọkan rẹ, sugbọn o di ọmuti ati alarinkiri. Iyawo rẹ si ti gba ọna ti ko tọ. Ati oo, ohun gbogbo ni o ti ṣẹlẹ si ọkunrin otoṣi yi.

76 Ati nigbati mo ji dide……. Ṣaaju ki emi to dide, Fletch sọ fun mi, o sọ fun mi ninu ala….. o wipe, “Billy, Emi yoo ba ọ wa ibikan, arakunrin Bill. O bọ́ awọn ọmọ mi nigbati ebi n pa wọn.” O wipe, o jẹ baba fun wọn. Emi yoo ba ọ wa ibi àyè nibiyi ti otutu ko fi ni pa ọ.“ A si jọ n rin lọ nibi ẹgbẹ ibiti awọn alarinkiri yi wa, ni ipari, a de ibikan, o si wipe, ”Emi yoo joko nibiyi.“

Mo si wipe, “Emi yoo rin siwaju nibẹ yẹn boya emi yoo ri ibi aye kan”

Mo si rin siwaju, mo si wo ibi okunkun, otutu mu pupọ ni alẹ naa. Mo si ronu, “Mo si rò nipa rẹ; Ni igba kan, Ọlọrun Olodunmare gba mi ni aye lati dari ijọ Rẹ. Ni igba kan, O jẹ ki n waasu Ihinrere Rẹ mo si ri awọn ọkan ti a gbala. Awọn ọkunrin ati awọn obinrin ti wọn wa lati gbogbo agbaye lati le ba mi sọrọ fun iṣẹju diẹ. Nibiyi ni mo wà bayi, mo jẹ alarinkiri, ko si ẹnikẹni ti o fẹ mi. Otutu si n mu mi. Kin ni ohun ti emi yoo ṣe? Nigba naa mo taji.

77 Mo sọ fun iyawo mi. Mo wipe, “Boya o tumọ si pe Fletch nilo ohun kan.” Nitorina a sare jade boya awa yoo ṣawari rẹ. Arakunrin rẹ si ri i. O n gbe ni ibiyi ni ibikan …. Pẹlu “awọn ọdẹ” Ni ita lọhun nibiti wọn ti n ṣowo awọn ẹsin ati orisirisi nkan. Mo tẹsiwaju. Mo rò, “O dara, jẹ ki n kan gba eyi laaye lati kọja lọ”

Nitorina……… Mo pada wa bayi, lati ilu Canada pẹlu ọgbẹni Fred ati awọn iyoku ni ọjọ kan. Ati ninu ọkan mi, mo ti pinnu, “Ti awọn eniyan wọnyi ko ba fẹ gbọ iwaasu mi, o dara, ko jẹ dandan fun wọn.” Mo ti waasu fun bi ọdun marun-un-le-logbọn. Ati ọdun mẹẹdogun si ọdun meji-din-logun. Emi ko ṣe ohunkohun bikoṣe ki n kan…… Oluwa Naa….. Mo ti gbiyanju lati gbe igbesi aye mi sunmọ Ọn ti emi ko si sọ ọrọ kankan ayafi ti O ba kọkọ sọ fun mi. Ohun gbogbo…….

78 Awọn eniyan sọ wipe, “Bayi, ti arakunrin Branham ba sọ fun ọ pe oun bọ wa, ranti, iwọ foju sọna fun ipade, nitoripe yoo wa ni orukọ Oluwa. Oun ko ni ṣe ohunkohun ayafi ti Oluwa ba sọ fun un…… ”Eyi jẹ otitọ. Emi yoo duro titi ti yoo fi sọ fun mi. Emi ko ni tẹsiwaju ayafi ti O ba sọ fun mi. Lẹyin naa eyi, ni bi awọn oṣu diẹ to kọja, Ko sọ ohunkohun fun mi nipa awọn ibiti emi yoo lọ.

Lẹyin naa mo pada de lati Canada Fred si sọ fun mi….. tabi Arakunrin Roy sọ fun mi àlá rẹ, bi oun ati Emi ati arakunrin Banks ti ṣe jọ n lọ papọ, ṣaaju ki a to pinya.

Ati lẹyin naa, ni ọjọ keji a de ọdọ arakunrin Fred ati ọmọ rẹ, Lynn ko si ni ile, nitorina ko le ba wa jade. Nitori naa oun ati iyawo rẹ ni lati duro. Ó gbé iyawo rẹ nibẹ ni agbegbe Rose wood…… tabi Elrose, Sakatchewan.

Emi ati Billy si wọ ọkọ agbegi ati arakunrin Fred. Ni alẹ ọjọ naa gbogbo oru ni a fi rin irinajo, ati ni ọjọ keji. Ni owurọ ọjọ keji, a ti fi agbegbe Helena, Montana silẹ, a si n bọwa si ibi ẹnu-bode.

Mo si la oju silẹ titi di bi agogo mẹsan oru si bẹrẹ si ni kùn mi. Mo si sùn. Ati Billy, o fẹ sun di bi agogo mẹwa ọjọ keji, nigbati imọlẹ owurọ ba tan. Nitorina eleyi dara fun wa lati rin irinajo.

79 Nitorina mo dide ni bi agogo mẹrin mo si bẹrẹ si ni wakọ. Billy si n sun. A lọ si ibikan mo si n ronu ninu ọkan mi. “Ṣe o mọ ohunkan? Ọkan ninu awọn ọjọ wọnyi, ni kete ti mo ba mu iyawo mi lọ sibẹ…… Emi ko ni sọ fun un ohun ti mo fẹ ṣe. Sugbọn ti emi ba de ibẹ. Lẹyin naa emi yoo sọ fun un, ”Emi fẹran ibiyi to bẹ ẹ gẹ, ko nilo ki a lọ si ibomiran mọ. Ẹ jẹ ki a kan, duro nibiyi“ A ti kuro ni ibi ọlaju ni bi ibusọ, ọgọrun mọkanla maili, kuro ni ibi-gbogbo. Ṣe ẹ ri? Lọna jinjin ni aginju. Mo ro, ”ọmọkunrin, ṣe eleyi ko ha dara bi? Emi ko nilo lati gé irun ori mi, emi ko nilo lati wọ aṣọ ni ọna to dara. Emi yoo kan jẹ ẹniti o maa n gun ori-oke.“ Ohun ti mo fẹran lati jẹ ni igba gbogbo.” Mo si wipe, “Mo ni awọn ibọn kan, ti awọn eniyan fun mi…… Emi yoo si di afinimọna ti o lokiki. Emi kan fẹran eleyi. Ati lẹyin naa, ti Oluwa ba sọ fun mi pe ki n jade lọ pe ẹnikan wà nibikan tabi ohun kan wa nibikan, emi yoo sare sita emi yoo si sọ fun wọn emi yoo si pada. Emi yoo si ran Bud lọwọ, a o si jọ ni ibiti o dara nibiyi.” Emi n ronu nipa eleyi.

80 A lọ si ile-ounjẹ lati lọ jẹun (ibi kekere kan ni ibi ori-oke) ni bi agogo meje. Akoko ti fẹ lọ, nitorina mo ji Billy dide. Epo moto ti tan, nitorina a ni lati ra epo bẹntirolu, a si lọ si ibi kekere yi, ibi ile-ounjẹ kekere yi. Nigbati a wa nibẹ, ọkunrin kan wa si ibi oju-popo, boya o fẹrẹ ju mi lọ die, sugbọn o dabi ọkunrin agba loju mi. O wọ aṣọ-awọleke iṣẹ, aṣọ awọleke iṣẹ ti òkè (Jakẹti) o wọ bata buutu ti a fi n rin, o si de fila dudu, irugbọn wa ni gbogbo oju rẹ bi eleyi (gbogbo rẹ funfun bi yinyin) irun n yọ lati abẹ fila ori rẹ ni ẹyin rẹ. Mo si ro, “Eleyi jọ ọkunrin kan” si mi. Ko jọ ẹni ti ko lagbara, ti o ya ọlẹ…… pẹlu siga ni ẹnu rẹ ti o gun bi eleyi, ti yoo si wọ ṣokoto penpe, ti yoo duro sibi adagun omi igbafẹ kan, ti ikùn rẹ si tobi bi ìkòkò bii ti awọn apá ila-oorun, gẹgẹ bi ……. Mo tọrọ gafara fun ohun ti mo sọ yi! Ṣugbọn, ọkunrin yi dabi akin kan si mi, ẹni lile, irisi-rẹ ko dara loju. O dabi ẹnipe o n gbe ni ibiti Ọlọrun da pe ki eniyan maa gbe. Mo si ni ifẹ rẹ.

81 O wọ inu ile-ounjẹ naa o si ni ki wọn fun oun ni akara-oyinbo… Awọn eniyan to bii mẹẹdogun, tabi ogun eniyan. O ni lati sín. Ṣe ẹ mọ bi awọn eniyan kan……. (Arakunrin Branham ṣe afarawe bi a ti maa n ṣe ti ẹnikan ba fẹ sín) (Mo tọrọ aforiji). Sugbọn o fi sínsín ọkunrin pipe ti ara aginju kan sita; ó dún bi Kerchooee! O dabi pe atẹgun fọ ohunkan. Nigbati o ṣe eleyi, ko si ẹnikẹni ti o le sọ ohunkohun. Rara, sa! Mo wipe, “Billy ọkunrin yẹn jẹ ẹni bi ọkan mi.”

O wipe, “Aa Baba, iwo ko gbọdọ fẹran lati ri bi eleyi……”

“Ohun ti…… ohun ti mo fẹ jẹ niyi ni ọjọ iwaju” Ṣe ẹ ri? Mo wipe, “Ohun ti mo fẹ jẹ.”

82 Mo si duro nibẹ fun igba diẹ, Billy wo mi o si tẹsiwaju lati maa jẹ akara oniyẹ-fun ti a yan ninu apẹ. Emi si ti jẹ ti ọdọ mi tan. Ni iṣẹju diẹ, ẹnikan, ti o wọ bata búùtù ni iwaaju wa gangan, pẹlu awọn patako kekere ni ẹyin bata buutu naa, emi ko le ri ayika. Ẹnikan dide ti o jọ ẹniti mo fẹran lati jẹ, bi ọmọ ọdun maarun-le-ni-aadọrin ….. ko sanra rara. O so aṣọ mọ ara, akisa. Ati ọ̀rẹ́ rẹ̀ ti o dide duro pẹlu rẹ jẹ Fletch Broy, gẹlẹ, irun funfun wa ni oju rẹ. Billy si wo yika, o wipe, “Baba awọn mejeji jọ iwọ ati Fletcher.” Ẹ ko le finu gbero rẹ bi o ti ṣe ri lara mi. Ati ẹni kekere naa, ri bi emi ẹniti ko ni okun. Wọn ti duro si ẹ̀gbẹ́ iná ti eefin si wa ni gbogbo ara wọn, wọn dọti. Mo ro ounjẹ owurọ wọn papọ…… ọkunrin naa ni lati san ogun kọbọ, boya fun ife t-í-ì kan tabi ohun kan, ọkan mi si mì ninu mi. Mo si wo. Billy si sọ wipe, “kini ohun ti o ṣẹlẹ si ọ”

Mo wipe, “Ko si ohunkohun” mo si n wo eleyi. Wọn si lọ yika, wọn si jade lọ.

O wipe, “Baba, kini ohun ti o ṣẹlẹ?”

Mo wipe, “Ko si ohunkohun”

O si wọ inu ọkọ. Mo wipe……

O wipe, “Ṣe o ṣi tun wu ọ pe ki o wa ọkọ lẹẹkan si?

Mo sọ wipe, “Rara”

O sọ wipe, “orun ṣi n kun oju mi”

83 Nitorina o lọ sun, mo si n sare wa ọkọ lọ ni oju popo ni iwọn marun-le-laadọta ibusọ mail ni wakati kan pẹlu ọkọ naa, ni ibi awọn ori-oke, mo si n wakọ lọ si ibi ẹnubode, mo n lọ…. mo n lọ si ile ni Arizona, sugbọn mo n lọ bayi si ilu Utah. Bi o si ti ṣe de ibẹ, ti mo n lọ laarin awọn ori-oke ni bi iwọn ogun maili kuro ni igboro…… Gẹgẹ bi o ti ṣe ri… ṣe ẹ gbọ nipa rẹ, gẹgẹ bi mo ti ṣe sọ fun yin, ni bi i owurọ nipa ọkẹrẹ ati awọn nkan wọnyi, bi awọn nkan…… ẹnikan bẹrẹ si i ba mi sọrọ, ohun kan gẹgẹ bi ẹ ti ṣe n gbọ mi. Mo mọ pe o dabi aṣiwere. Sugbọn mo ni lati ṣalaye rẹ….. ṣe mo ti sọ ohunkohun fun yin tẹlẹ ri ayafi ohun ti o jẹ otitọ? Ohùn kan si bẹrẹ si ni sọrọ. Emi naa si n ba ohùn naa sọrọ.

O wipe, “Ṣe gbogbo awọn ipinu rẹ, iwọ yoo si dabi eleyi.”

Mo wipe “Oluwa, emi ko fẹ dabi eleyi.”

O wipe, “Iyawo rẹ yoo lọ pẹlu, oun ko ni gbé ibi awọn ori-oke bi eleyi. Iwọ yoo si di alarinkiri gẹgẹ bi o ti ṣe ri ninu ala, iwọ yoo”

Mo wipe, “Emi ko fẹ ri bi eleyi, sugbọn nkan ti….. emi, ko fẹ gbe igbesi aye mi bi eleyi. Mo fẹ ṣe ohun ti o yatọ. Sugbọn a sọ fun mi pe O pe mi lati jẹ wolii, mo si fẹ lati maa gbe ninu aginju gẹgẹ bi awọn wolii” Mo n lo awọn awawi mi ki emi ba le ri aye lati sọdẹ, anfani ara mi.

O si wipe, “ṣugbọn awọn wolii inu majẹmu laelae ni eleyi. A ti pe ọ si ipo giga ju eleyi lọ. O wipe ”O ni ọpọlọpọ ẹbun yatọ si nkan yi. A pe ọ lati gbadura fun awọn alaisan ati pe ki o waasu ihinrere. Ati ninu ìpè Aposteli, O mọ awọn ohun nla, o si ni ọpọlọpọ ẹ̀bùn.“ O wipe, ”kini idi ti iwọ fi maa n duro de Mi, lati tì ọ siwaju nigbagbogbo ti o ba tẹsiwaju? Kini ere rẹ? Lẹyin naa mo ri i……. Ati lẹyin naa O sọ wipe, “Ṣe o ranti? Mo sọ fun ọ ni ana. Ṣe o ranti ohun ti arakunrin Roberson sọ fun ọ ninu ala rẹ, ninu ala rẹ, tabi iran? Pe o ti ṣe gẹgẹ bi Mose ti ṣe. O ti gbagbe irora awọn eniyan rẹ. O ti gbagbe ipe ti Mo fi pe ọ.

84 Mo jẹ ki awọn alaisan dubulẹ. Mo fẹ ki Oluwa sọ fun mi ibiti mo gbọdọ lọ ati ibiti emi ti ko gbọdọ lọ. Eleyi kuna. Mo ti mọ odi yi ara mi ka nitori pe awọn eniyan ko gbọ iwaasu mi. Ti iwọ ba fẹ…… ki Ọlọrun ma jẹ ki o ṣẹlẹ pe emi yoo gbiyanju lati ṣe afiwe igbe aye isisiyi si ti Mose, sugbọn o jẹ ohun ti Mose ṣe gẹlẹ. Awọn eniyan ko tẹti si i nigbati o wa lati gbà wọn nitorina, o kan fi wọn silẹ ni. O si wọ inu aginju lọ sugbọn Ọlọrun yi-i pada. O si ti gbagbe gbogbo irora awọn eniyan naa.

Lẹyinnaa, mo wipe, “Oluwa, ti o ba jẹ wipe…… Bawo ni emi….. eleyi jẹ otitọ! N ko ni ẹkọ kika kankan, sugbọn ẹkọ girama nikan, bawo ni yoo ṣe e ṣe ……. Ati awọn eniyan naa ti wọn tò ni awọn ori-ila ati ni ibi gbogbo, lati gbọ iwaasu ihinrere ti o rọrun.” O jẹ ohun ti o ga julọ. O ga nisisiyi ju ohun ti o wa nigba majẹmu atijọ. O goke lọ ọrun O si fi ẹbun fun awọn eniyan. Ṣe ẹ ri? Jesu Kristi ọkanna ni ana, ni oni, ati titi lae. Lẹyin naa mo n ronu, mo si gbọ ti O n ba mi sọrọ. O si kuro ni ọdọ mi.

85 Mo si sọ wipe, “Billy” O si ti sùn lọ fọnfọn. Mo si wipe, Billy, ṣe iwọ ni?“ Ko si dide rara.

Mo si ro, “Oluwa Ọlọrun ……..” (Mo dín ere ọkọ mi ku)“……… kini ohun ti eleyi tumọ si?”

Mo si wipe, “Billy! Billy!”

O wipe, “Kin ni ohun ti o fẹ?”

Mo si wipe, “Ṣe iwọ ni o n ba mi sọrọ?”

“Rara, kilode?”

Mo si sọ wipe “Mo fẹ sọ ohun kan fun ọ. Mo la ala kan ni aipẹ. Ṣe o ranti ọmọkunrin yẹn pe o jọ emi ati Fletch? Bere lọwọ mama nigbati a ba pada si ilu Tucson, mo sọ ala yi fun un. Ati pe Billy, ohun kan n ṣẹlẹ. O si n lọ lọwọlọwọ bayi. Ohun kan ba mi sọrọ mo si ro pe iwọ ni.”

86 O si wo mi ni ọna ajeji, o si duro diẹ…. A si n wakọ tẹsiwaju, nitorina…… lẹyin iṣẹju diẹ….. o si pada sùn lẹẹkansi. Mo si n ronu nipa rẹ bi mo ṣe n wakọ lọ. Kini ohun ti eleyi tumọ si? Mo si n wakọ lọ ni oju-ọna ati ni…… Ati lojiji, O si tun pada wa, O si n ba mi sọrọ lẹẹkansi.

O si wipe, “Pada! Ṣe Emi ko sọ fun ọ ni ibẹrẹ pe ki o ṣe iṣẹ ajihinrere? Nigbati Mo pe ọ ni ibi odo, ṣe Emi ko sọ fun ọ pe, Gẹgẹ bi a ti ṣe ran Johanu onitẹbọmi lati kede bibọ akọkọ…….. Ṣe Johanu ko ha ju wolii kan lọ bi? Jesu funrara Rẹ sọ bẹ ẹ. ”Kinni ohun ti ẹ jade lọ wo, wolii kan?“ mo sọ fun yin, ”o ju wolii lọ“

87 Lẹyin naa gbogbo rẹ bẹrẹ sii tọ mi wa. O wa jẹ ohun iyanu fun mi. Lẹyin naa O ran mi leti nipa awọn eniyan naa lẹẹkan si. Bawo, ṣiṣe ohun ti Mose ṣe, bawo ni Mose yoo ṣe de ọdọ awọn eniyan naa ninu aginju? Bawo ni emi yoo ṣe de ọdọ awọn eniyan nigbati mo ba wa ninu aginju? Ohun kanna gẹlẹ. Lẹyin naa O wa si…… eleyi iwe Timoti keji ori kẹrin. Ẹ ranti igba ti a ya ijọ si mimọ ni owurọ ọjọ naa ni ọgbọn ọdun sẹyin (ẹyin olujọsin atijọ) nigbati O fi awọn igi kan han mi ti mo si gbin wọn si ẹgbẹ mejeeji? Ṣe ẹ ranti eleyi? Ṣe ẹ ranti iran naa. A kọ gbogbo rẹ sinu awọn iwe ati awọn ohun ti a gba silẹ ati ninu ohun gbogbo. O ti jẹ ọpọlọpọ ọdun sẹyin bayi, Bi mo ti ṣe ri awọn nkan wọnyi ti emi ko si ṣe idapọ laarin isọkan ati mẹtalọkan. Mo duro ni aarin wọn, mo si gbin awọn igi wọnyi, awọn igi meji wọnyi nikan ni o ni eso. Ati emi……. Gbogbo awọn igi naa ni o ga soke ni bi iwọn ọgbọn ẹsẹ bata wọn si dawọ gigun duro. Wọn si ga de ọrun. Wọn ni ẹka bakanna. Ṣe ẹ ri? Ọkan ni apa kan ekeji ni apa keji, mo si ge wọn. Ṣe ẹ ranti iran naa. Ṣe ẹ ri? A kọ wọn sinu iwe, o si wa ninu iwe itan igbe aye mi ati gbogbo rẹ. Wọn si ga de ọrun bi eleyi, ni kiakia. O si wipe “Na awọn ọwọ rẹ fun eso naa.” Lẹyin naa mo ri eso kanna ni ibi agbelebu nigbati mo sare lọ sibẹ. O si sọ wipe, “Ṣe iṣẹ ajinyinrere. Fi idi iṣẹ iranṣẹ rẹ mulẹ. Akoko yoo de nigbati wọn ko ni le farada ẹkọ opomulero ti o ye kooro. Maṣe fi wọn silẹ nigba naa, maa tẹsiwaju” Gbogbo rẹ ni o wa sinu ọkan mi.

88 Ati lẹyin naa mo ranti, Marily Monroe yi, obinrin ti mo ri pe o ku ti mo si ti ri ṣaaju ni ọsẹ kan ṣaaju ki o to ṣẹlẹ. Bi wọn si ti ṣe sọ wipe o pa ara rẹ, nigbati ko ṣe bẹ ẹ, mo ti sọ nipa rẹ fun wọn tẹlẹ, ohun ti yoo ṣẹlẹ o si ri bẹẹ, gẹgẹ bi o ti ṣe ṣẹlẹ si awọn ti o n ja ijakadi ni ibikan, ẹnikan yoo pa ẹnikẹji rẹ. Mo ṣe aṣiṣẹ nipa ọmọbinrin yi. Ọmọbinrin miran wa nibẹ. Ibatan rẹ ni ọgbẹni Danny Henry. Kini orukọ rẹ? Jane Russell… ibatan rẹ, ọmọkunrin ara ijọ onitẹbọmi.

Mo si n waasu ni ilu Los Angeles ni ibi àsè owurọ awọn ọkunrin oniṣowo. Mo si duro nibẹ mo si n sọrọ nipa awọn ẹgbẹ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ, ọkunrin kan ti o jẹ ọga awọn ijọ Assembili si wa nibẹ ati ọpọlọpọ awọn eniyan olokiki ni o pẹjọ papọ sibẹ. Ati nigbati mo sọrọ tan ti mo si fẹ fi aga-iwaasu silẹ ti mo n mura silẹ…. Nitoripe a n fi iwaasu naa ranṣẹ si jakejado orile-ede lati ipasẹ ẹrọ redio, mo si ni lati yi pada. Ni aarin yiyi pada yi nigbati wọn ko fi ohùn sinu ẹrọ redio, lẹyin naa, ki wọn wa fi ohùn ti wọn gba silẹ yi sita, ki wọn si padawa ki wọn si kede ile-iṣẹ redio ti wọn lò, mo si wa ni Clifton's nibiti a ti jẹ àsè owurọ wa. Bi mo si ti n rin jade kuro lati ibi pẹpẹ si isalẹ, ọkunrin kekere kan ti o rẹwa loju ti o to bi ọmọ ọgbọn ọdun, o sare si ta, o si fi ọwọ rẹ di mọ mi. O si wipe, “orukọ mi ni Danny Henry.” Lai mọ wipe arakunrin rẹ ni o n fi ohun ti a gbà silẹ sita lati inu ẹ̀rọ. O si maa n ba awọn ẹgbẹ ọkunrin oniṣowo gba ohùn silẹ (orukọ rẹ ni Jane Russell, oṣere ere-ori-itage naa…. ibatan rẹ. Iya rẹ jẹ oniwaasu Ijọ Afede-ajeji-ṣẹri Ẹmi Mimọ.)

89 Ati lẹyin naa, nigbati emi ….. o bẹrẹ sii sare wa si ọdọ mi, o si di mọ mì, o wipe, “Ki Ọlọrun ko bukun fun ọ, Arakunrin Branham” O wipe, “Mo nireti pe eleyi ko ni dabi alakatakiti ẹ̀sìn, sugbọn ni ọna ti emi gba ri, iwaasu naa le jẹ iwe ifihan ori kẹta-le-logun”. Nigbati o sọ eleyi, o bẹrẹ sii fi ede miran sọrọ. Ọmọkunrin ti ko ti gbọ iru nkan bayi ri, ọmọ ijọ onitẹbọmi. Ati ni kete…… oju rẹ funfun, o si wo mi, ohun ko mọ ohun ti yoo ṣe. Awọn ọkunrin wa nibẹ. Ṣe o wa nibẹ, Fred? Awọn melo ni o wa nibẹ ni akoko naa? Bẹẹni, meji tabi mẹta wa nibiyi, wọn wa nibẹ ni akoko naa. Ko si mọ ohun ti yoo sọ.

Obinrin nla kan, ọmọ ilu Faranse si wa nibẹ. O dide duro, o si wipe, “kilode, eleyi ko nilo itumọ kankan” o wipe, “Eleyi jẹ ede Faranse pọnbele.”

Ọmọkunrin naa sọ wipe, “Ẹmi ko mọ ọrọ kankan ni ede Faranse.” Obinrin naa si ti kọ ohun ti o sọ silẹ.

Ọkunrin kan si wa ni ibi igun gbọngan naa, o wipe, “otitọ ni eleyi jẹ. Mo ti kọ ohun ti o sọ silẹ ede Faranse ni”

Ni ẹyin lọhun patapata, ọmọkunrin ti oju rẹ ri gbọọrọ ti o si rẹwa, o duro ti ara ogiri, o si wa si iwaju, o ṣe ayẹwo gbogbo awọn iwe ti awọn eniyan naa ti kọ. O jẹ ogbufọ fun agbarijọpọ isọkan awọn orilẹ-ede, ni ede Faranse. Orukọ ọkunrin ti o wa nibiyi si n jẹ Victor LeDeux, ti ara ijọ Aine Vick ni agbegbe naa, o si kọ eleyi silẹ. Mo si ni itumọ rẹ lọwọ.

90 Ẹ tẹti si eleyi ti emi ba lee ka a:

Emi, Victor LeDeux, mo jẹ ọmọ-bibi ilẹ Faranse, mo si jẹ atunbi Kristẹni, ti a si kun pẹlu Ẹmi-Mimọ. Adirẹsi mi ni 809 North King Road, Los Angeles 46. Mo n jọsin ni ile ijọsin ti a n pe ni Tẹmpili Bẹtẹli, Oluṣọ-aguntan Arne Vick ni Oluṣọ-aguntan.

Itumọ tootọ ti mo jẹri nipa rẹ, ti isọtẹlẹ ti a sọ nipa Arakunrin Branham, eyiti Danny Henry sọ ni ede Faranse, oṣu keji, ọjọ kọkanla, ọdun 1961, ni ibi àsè-owurọ ti agbarijọpọ awọn ọkunrin oniṣowo. Itumọ tootọ isọtẹlẹ naa niyi.

Bayi ohun ti o sọ niyi:

Nitori iwọ ti yan ọna tooro naa, ọna ti o lagbara naa, iwọ ti rin ni iyan tirẹ (Bayi Emi le ri eleyi. Mose ni lati

ṣe iyan tirẹ pẹlu, ṣe ẹ ri?)

Iwọ ti yan ọna pipe ati ọna otitọ naa (ipinu ti o dara) eleyi si jẹ ọna Mi. (O fa ila si abẹ ọrọ yi "Ọna Mi" Emi Mimọ ni O n sọrọ pada bayi)

Nitori ipinu ti o gajulọ yi, ipin nla ti ọrun n duro de ọ…… o duro de ọ.

Iru ipinu ologo wo niyi (Bayi, tẹti silẹ daada)……. Iru ipinu ologo nla wo ni iwọ ṣe yi. Eleyi ninu ara rẹ̀ ni yoo jẹ ki, o wa si imuṣẹ iṣẹgun nla ologo naa ninu ifẹ pipe.

91 Ṣe o ṣe akiyesi, o maa jẹ wipe, ọrọ-iṣẹ ni o kọkọ ma n wa niwaju lẹyinnaa ni apọnle-ọrọ-iṣe. Ṣe o ri? Awọn ara ilu Faranse. Bayi ogbufọ ti agbarijọpọ isọkan orile-ede sọ itumọ eleyi, ọmọkunrin yi ko si mọ ọrọ faranse kankan. Ko ti gbọ ohunkohun bi ki a fi ede tuntun sọrọ. O jẹ ọmọ Ijọ onitẹbọmi. O kan ṣeṣi wa sibẹ ni ki o si gbọ orin yẹn, o si sọ wipe o wa sibiyi, ki o si gbọ iwaasu mi.

Bayi……… "Ninu ifẹ pipe" ……… ifẹ pipe. Bawo ni eleyi yoo ṣe jẹ ifẹ pipe ti ko ba ki n ṣe Ẹmi Mimọ? Ẹmi Mimọ jẹ ifẹ pipe.

92 Bayi…… bi emi ati Billy ti ṣe bẹrẹ sii lọ ni oju ọna….. Ṣe ẹ ri, a bẹrẹ sii lọ ni oju ọna naa, Billy si tun pada sun lẹẹkan si, o si wipe, "Emi yoo fun ọ ni ami ayeraye kan."

Mo si wipe, "Oluwa, kini…….. "Mo duro fun ìgbà diẹ ko si si ohun ti o ṣẹlẹ. Mo si wipe, "Kini ami ayeraye naa, Oluwa?" Mo si duro fun iṣẹju diẹ. Ati lẹyin naa…… Mo si wo lati ri Billy, o ti sun.

O si wipe, "Emi yoo fun ọ ni ami ayeraye kan" Lẹẹkan si. O wipe. "Wo apa iwọ-oorun lati ibi ti o wa."

Mo si yi ori mi bi eleyi ninu ọkọ naa lati wo (mo din eré ọkọ naa ku ṣe ẹ mọ) ….. Ati Oo, akika, Ẹmi Oluwa …. O dabi ẹnipe ki emi ki o kigbe ati bi pe ki emi sọkun. Mo si wo, mo si ri oke kan ti tente ori rẹ funfun. Mo si wipe, "Emi ko mọ…. emi ko ri ami ayeraye kankan nipa eyi."

O wipe, "A kọ orukọ rẹ si gbogbo rẹ yika"

Oo, Mo ro, "Kini ohun naa?" O si rẹ mi de inu, mo si bẹrẹ sii duro.

Billy si dide o wipe, "Kinni ohun ti o n ṣẹlẹ si ọ?" Mo fa ọwọ mi bi eleyi; oogun bẹrẹ sii jabọ lati, ọwọ mi, bẹ ẹ si ni yinyin wa.

93 Mo wipe, "Billy, ohun kan n ṣẹlẹ. Ni igba kan mo mọ ibiti mo ti kuna. Mo mọ wipe mo ti ja Ọlọrun kulẹ. O si dabi wipe mo n gbọ ti a n kọ orin naa ti mo si ri ẹgbẹgbẹrun oriṣiriṣi eniyan arọ, amukun, afọju ati awọn ti ẹya-ara wọn ko pé. Mo n gbọ ohùn awọn akọrin kan, o dabi ohun nla kan ti o lokiki ti o n kọrin.

Aimọ, aimọ! Ẹmi eṣu le jade.

Oun (Ṣe ẹ mọ orin naa)

Gba Jesu de, o da onde silẹ.

Mo le ri ila awọn alaisan ti wọn wa ni ibi gbogbo. Mo si ni lati duro. Billy ko mọ ohun ti o n ṣẹlẹ, mo si woke.

94 Mo si duro mo si wo ori oke mo si ri awọn oke meje. Ati nibiyi ti o ba fẹ ri ohunkan! Awọn tente meje ni o wa ni ori oke kan, oke ẹyọkan, ti o gun gbọọrọ lọ fun ọpọlọpọ ibusọ. Oke ti o gbẹyin ki o to de ilu miran. Ko si oke miran mọ lẹyin eyi. O si lọ lati ila-oorun si iwọ oorun, oke naa duro. Yinyin si wa ni ori rẹ.

Tente kekere meji akọkọ, ati lẹyin naa tente ti o tobi kan…. Lẹyin naa tente miran ti o kere, ati lẹyin naa tente nla - ti o tobi - ti o gùn gbọọrọ yinyin si wa ni ori oke naa. Mo si wipe, "Oluwa, emi ko loye ohun ti nkan wọnyi tumọ si"

O wipe, "Tente melo ni o wa nibẹ?"

Mo wipe, "Meje ni o wa nibẹ "Lẹta melo ni o wa ninu orukọ rẹ?"

B-r-a-n-h-a-m M-a-r-r-i-o-n B-r-a-n-h-a-m

95 Awọn tente mẹta ti o tayọ si wa. O wipe, "Awọn tente mẹta wọnyi. Jẹ onfa akọkọ, ekeji ati ẹkẹta. Onfa akọkọ jẹ ipa akọkọ ninu iṣẹ-iranṣẹ rẹ, tente oke kekere lẹyin naa onfa rẹ akọkọ, o ga diẹ." Ṣe o mọ, àmì ni ọwọ́. Lẹyin naa alafo diẹ wa nibẹ, akoko ti mo n lò lati fi simi nigbati o rẹ ara mi. Ọpọlọpọ ninu yin ni o ranti eyi. Ati lẹyin naa ni imọ-ẹmi-yatọ, onfa keji. Nisisiyi, emi ti ni omiran, bi i….. Awọn ọdun diẹ nibiyi o dabi awọn

tente kekere. Ṣe ẹ ri, ni ẹyin, gẹgẹ bi iṣẹ-iranṣẹ mi ti ṣe ri nigba naa. Ati lẹyin naa ni onfa kẹta wa.

Onka mẹta tumọ si pipe. Ṣe ẹ ri? Ẹkẹta naa. Tẹnte ti o tẹle jẹ marun-un o jẹ onka ti ore-ọfẹ. Tente ti o si tẹle jẹ meje, o jẹ onka pipe, opin. "Ọjọ mẹfa ni ẹyin yoo fi ṣe iṣẹ, ọjọ keje jẹ sabbati, opin ọsẹ, opin àkokò." Ṣe ẹ ri? Mo si duro mo si fi eleyi, han Billy. Mo si wo wọn.

O wipe, "Eleyi…… jẹ ki eleyi ki o daju. Ti iyemeji ba wa ninu ọkan rẹ, ranti ibiyi, pada wa ibiyi".

96 Billy si gba mi ni ejika, o wipe, "Baba, wo apa ila-oorun!" Bi o ti ṣe ṣẹlẹ emi ko mọ, sugbọn ni apa ila-oorun ọna yi ni ibiti a ti n jo idọti wa. Ni ọpọlọpọ maili ati maili si eyikeyi ilu kankan, ibi idalẹ-si nla kan ti o ga ti o wa nibẹ ni apa òsì oju-ọna naa.

Emi n pada si Ori pápá ihinrere. Amin. Agbalagba tabi ọdọ, ni yiye tabi ni kiku, Emi yoo gbọran si Ọlọrun titi ti iku yoo fi tu mi silẹ. Mo ti ja Oluwa kulẹ….. N ko fẹ. Boya mo ṣe…… Mo ti gbiyanju ……. Ẹ jẹ ki emi mu eyi wọle. Ṣe ẹ ri? (Aye ṣi wa ninu Kasẹti ti a fi n gba ohun silẹ) Jẹ ki emi fi eleyi si i, mo ti nifẹ, mo ti nifẹ lati ri Jesu Kristi ti a fihan laisi abuku kankan. Si jẹ ki awọn ara ti o ba gbọ ohùn yi ati ijọ yi ki o ranti pe, lati ọjọ yi lọ, idi ti ẹ ko ṣe ni abuku kankan ati idi ti o fi jẹ wipe nigbogbo awọn ọdun wọnyi ….. o ko le sọ ohun kan ti a ti sọ tabi ti a ṣe sugbọn o jẹ ohun ti o ṣẹlẹ. Mo pe ẹnikẹni nija ki o mu ọkan lara ọpọlọpọ awọn ohun ti o wa lati ori pẹpẹ yi ati awọn imọ ẹmi-yatọ, ati awọn isọtẹlẹ ohun ti yoo ṣẹlẹ….. O ṣẹlẹ ni pipe gẹlẹ; Bayi, ti ijọ ba gba eleyi gbọ, sọ wipe "Amin." Ko si ẹnikẹni ni gbogbo agbaye yi ti o le fi ẹyọkan han mi. Sugbọn jẹ ki o di mímọ̀ fun ijọ nibiyi ati ijọ ti o n bọwa. Ti Ọlọrun ba ti ọkunrin kan pe ki o gba inu ọpa kan kọja ti ko ba si mira rara ayafi ti Ọlọrun ba sọ fun un, ko si igbagbọ. O jẹ wipe Ọlọrun ni O n ti ọ pe ki o ṣe ohun kan. O si ti kọ́ iṣẹ-iranṣẹ naa de ibi pe ko si ẹnikẹni ti o le sọ ohunkohun lodi nipa rẹ. Sugbọn lati isisiyi lọ, jẹ ki emi kọkọ ba yin sọrọ ni orukọ Oluwa, ṣaaju ki o to tẹti, nitoripe mo gbọdọ jade lọ nipa igbagbọ. Mo gbọdọ Ṣe e nipa igbagbọ boya mo ronu rẹ pe o tọ tabi ko tọ, tabi ohun kan….. mo ṣe eyi ti o dara ju ninu iyan mi ati lẹyin naa lọ ṣe e. Nitoripe ko kuna ri, o jẹ nitoripe mo ti duro titi di igba ti yoo sọ fun mi pe ki emi ki o lọ ṣe e. Mo ti duro de E nitori naa kii ṣe emi, o jẹ Oun.

97 Sugbọn ṣe ẹ ri, Paulu nla naa paapa de aarin iṣoro ni igba kan. Ati ni ọpọlọpọ igba ni Ọlọrun ti ṣe awọn ohun kan tabi ti yoo gba awọn iranṣẹ Rẹ lati ṣe e, eyiti yoo jẹ asiṣe, ni ọna lati fi idi awọn nkan wọnyi mulẹ. Nisisiyi a mọ wipe awọn eniyan le e ṣe asiṣe, sugbọn Ọlọrun ko le ṣe asiṣe kankan. Sugbọn, ti mo ba lọ si papa ihinrere, ti mo si n lọ ni ọna ti mo fi n lọ yi, lẹyin naa mo gbọdọ ṣeto awọn ipade siwaju ki, n si ṣe ohun gbogbo ni titọ. Boya akoko nla ti o n bọ naa niyi, eyiti a ti n foju sọna fun. Dajudaju, ti o ba jẹ wipe ohun ologo naa niyi ninu ara rẹ eyiti yoo mu wa si imuṣẹ, iṣẹgun ologo naa ninu ifẹ pipe (eleyi si ni ọrọ-ise ṣaaju ọrọ-apọnle ọrọ-iṣẹ) lẹyin naa eleyi jẹ ifẹ pipe ẹyiti o jẹ Ọlọrun. Ṣe ẹ ri? Yoo si gba ifẹ Ọlọrun lati jade sita nibẹ ni ibi ìlà ti o wa niwaju ki o si duro laarin alafo fun awọn eniyan naa.

98 "Ati awọn ọmọ buburu wọnyi" wọn jẹ …… wọn dagunla si Ọrọ naa, mo si pe wọn ni ọmọ buburu"…… Ọlọrun fi ye mi wipe emi ko gbọdọ ṣe eleyi nitoripe awọn ni…… Ọpọlọpọ ninu wọn ni o jẹ ọmọ Rẹ. Mo jẹ….. wọn ko le ran ara wọn lọwọ nitoripe wọn huwa ni ọna ti o yatọ to bẹẹ gẹ. Ọpọlọpọ awọn ijọ atijọ wọnyi ti wọn tutu ti wọn si jẹ eleto ni wọn de wọ́n mọlẹ, ẹmi yi si wa lori wọn, wọn si wa ninu tubu to bii igba ti Israeli wa ninu tubu. Gẹgẹ bi Mose ṣe lọ gba wọn silẹ kuro ninu oko-ẹru… Awọn eniyan ti wọn nifẹ Jesu Kristi, yoo si sin In ti wọn ba mọ bi wọn yoo ṣe sin In: Wọn si wa ni igbekun labẹ awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ ti wọn sọ fun wọn pe "Maṣe ṣe eleyi" ati "maṣe ṣe tọun"

99 Sugbọn ipe Ọlọrun gbọdọ wa, "Ẹnikẹni ti o ba nifẹ lati tẹsiwaju si ilẹ ileri, jẹ ki o tẹsiwaju!: A wa ni oju-ọna wa si ilẹ ileri. Amin. Jẹ ki wọn wa ki wọn si tẹsiwaju. A wa ni oju-ọna wa lati pade Kristi ni opin ọjọ yi. Mo si fẹ mu eleyi tọ yin wa ki ẹ ba le ri, ki n si fi han fun yin pe….. aṣiṣe ti eniyan le e ṣe, sibẹ ki o si jẹ olootọ pẹlu rẹ.

Mose padanu imọlara fun awọn eniyan Rẹ nitoripe wọn ko tẹti si I. Ati Arakunrin Roy, ṣe o ti ri ala rẹ? Ati nisisiyi, emi ko lee lọ, pẹlu iru iṣẹ-iranṣẹ bi eleyi, ayafi ti emi ba ni imọlara ti o yatọ ninu ọkan mi nipa rẹ. Ohun yoowu ti Ọlọrun I baa sọ fun mi. Sugbọn iyipada naa niyi ti Arakunrin Roy…… (eyiti o ri pe o n bọ) ohun kan gbọdọ yimi pada nitoripe emi, ninu ọkan mi, ti mo ba jade lọ sita nibẹ ti mo si ni imọlara bi mo ti nṣe bayi….. emi yoo ṣi tun maa ro wipe o yẹ ki wọn gbọ iwaasu naa, o yẹ ki wọn ṣe …. Emi ko si ni imọlara ti o yẹ ki emi ni fun awọn eniyan naa. Titi di igba ti emi yoo fi ni iru imọlara yi ko nilo ki emi jade lọ nitoripe emi yoo jẹ alagabagebe.

100 Ati ni gbogbo awọn ọdun wọnyi sẹyin mo ti gbiyanju lati sin I pẹlu ọkan otitọ, emi ko si ni jade lọ sita nibẹ gẹgẹ bi alagabagebe. Mo ni lati ni imọlara yi, pe ko ki n ṣe awọn "ọmọ buburu" ko ki n ṣe iru ẹgbẹ awọn eniyan wọnyi…….. o jẹ awọn ọmọ Ọlọrun ti wọn wa ninu igbekun, emi gbọdọ lọ si ọdọ wọn. Ayafi ti mo ba ni iru imọlara yi, emi yoo kan maa rin kiri ni. Waasu ni awọn agọ-ajọ kan ati awọn nkan, sugbọn duro.

101 Mo ni orin kekere kan. Emi ko le kọrin. Ẹmi a kan tun un kà fun ẹyin ará, a ti ṣeto rẹ silẹ. Ẹmi ko le e ka, sita daada. Wọn ko kọ ọ silẹ daada. Emi ko mọ boya emi le ka a tabi emi ko le e ka a . A kọ ọ silẹ ni ọna orin.

Ogo! Ogo, halleluyah! (Ṣe ẹ ti gbọ ọ)

Ogo! Ogo, halleluyah! (Melo ninu yin….. Ni tootọ a ti gbọ ọ rí)

Oniwaasu naa ti n gẹsin yika gbogbo ilẹ

Pẹlu ibọn le'jika rẹ ati Bibeli lọwọ

O rohin faraye nipa ilẹ ileri kan

O si n kọrin bo ti ṣe n lọ

Mo n sinmi le E

Mo n sinmi le Apa Oluwa

Mo n sinmi le E

Mo n sinmi le Apa Oluwa

O waasu nipa idajọ ina ati sufuru ti n bọ.

Ati ogo Ainipẹkun lọrun fawọn ta da lare

Bo ti n gẹsin lati oke doke ninu irin ajo rẹ

O nkọrin didun yi

Agbara nbẹ O nbẹ to n ṣiṣẹ iyanu

Ninu Ẹjẹ Ọdọ-aguntan

Agbara nbẹ O nbẹ to n ṣiṣẹ iyanu

Ninu Ẹjẹ Ọdọ-Aguntan.

102 Oniwaasu atijọ naa ti o n gẹsin yika. Ṣe ẹ ranti rẹ. Ṣe ẹ ri?

Bayi ibọn rẹ ti darugbo ni ibiti a fi kọ si;

Eruku ti bo Bibeli rẹ nibi ta fi pamọ si (Eyi jẹ otitọ)

Sugbọn ọrọ iwaasu rẹ yoo pade wa nikẹyin

Otitọ Ọlọrun n gbilẹ si.

Ogo! Ogo, Halleluyah!

Ogo! Ogo, Halleluyah!

Ogo! Ogo, Halleluyah!

Otitọ Rẹ n gbilẹ si.

103 Emi yoo kọ eleyi. Mo wa ni iduro ni owurọ yi nigbati mo n kọ eleyi silẹ, mo gbe ọwọ mi le ibọn atijọ naa ti a gbe kọ si ara ogiri, Mo ronu pe ko ni pẹ mọ.

Ibọn rẹ ti darugbo

Nibiti a fi kọ si (eyi jẹ otitọ)

Eruku ti bo Bibeli rẹ nibi ta fi pamọ si

Sugbọn iwaasu Bibeli rẹ……

yoo pade wa nikẹyin.

Otitọ Rẹ n gbilẹ si.

Otitọ Ọlọrun lati inu Bibeli yi. Bẹẹni, Jesu Kristi Ọkanna ni lana, loni ati titi lae.

104 Oniwaasu atijọ naa ti o n gẹsin kiri pẹlu ibọn rẹ ni ẹyin rẹ, Bibeli rẹ ni ọwọ rẹ, o n gẹsin kiri gbogbo ilẹ, o

si n lọ kaakiri ori-oke, o si n lọ si gbogbo awọn pẹtẹlẹ ati ibi gbogbo, o n waasu ijọba ẹgbẹrun-ọdun ti o n bọ, ati idajọ ti o lẹru fun awọn alaimọ, o si n waasu ijọba Ọlọrun fun awọn eniyan rere. O jẹ otitọ. Ibọn atijọ naa ti a n pe ni Winchester ti n bajẹ lọ. Ati Bibeli naa, wọn ni awọn iwe ibalopọ kan dipo rẹ. Sugbọn otitọ Ọlọrun si n tẹsiwaju si. O jẹwọ ara Rẹ pe Oun jẹ otitọ bakanna loni, o si fi idi eleyi mulẹ, pe Oun wa bakanna titi

Otitọ Ọlọrun n gbilẹ si

Ogo! Ogo! Halleluyah!

Ogo! Ogo! Halleluyah!

Ogo! Ogo! Halleluyah!

Otitọ Rẹ n gbilẹ si

105 Kini-idi? Ẹnikan yoo gba a. Nitori Jesu Kristi jẹ ọkanna lana, loni ati titi lae. Ẹ jẹ ki a kọrin yi lẹẹkansi. Bayi, a ni orișiriși nibiyi, awọn ọmọ ijọ Mẹthọdisti, ijọ Baptisti, ijọ Luther, ati awọn miran……. Nigbati a n kọ ègbè rẹ ti o gbẹyin, ẹ jẹ ki a bọwọ pẹlu ẹnikan ti o wa ni ẹ̀gbẹ́ rẹ, lẹyin naa a o tuka.

Nisisiyi, ẹ ranti, ẹyin ti ẹ o pada si ile-ijọsin yin, ẹ lọ ni aṣalẹ yi. Ẹ bami ki Oluṣọ-aguntan yin. Ẹ si gbadura fun mi, ẹni kọọkan yin. Ati lẹyin naa lẹẹkansi, mo fẹ ki ẹ ranti, ti ẹ ko ba ni ibiti ẹyin yoo lọ (Ṣe o ni ohunkohun?) ……… Lẹyin iwaasu Arakunrin Neville ni aṣalẹ yi, lẹyin ti o ba ti ṣe iwaasu rẹ, lẹyin naa mo fẹ ṣe gbigba ohun iwaasu silẹ ti a o pe ni Itanṣan Ina Pupa Ti Bibọ Rẹ. Ẹyin, ṣe ẹ ri? Ni aṣalẹ yi. Ki Oluwa ko bukun fun yin, nisisiyi. Ati ni ọsẹ ti o n bọ̀, Emi…… ọjọ isimi ti o n bọ, ti Oluwa ba fẹ, o ṣeeṣe ki n pada wa lẹẹkansi lati gba ohùn iwaasu miran silẹ nitoripe mo ni lati wa ni ilu Arkansas ni ọsẹ ti o n bọ yi.

106 O dara, nisisiyi, ẹ jẹ ki a kọrin lẹẹkan si ki a si bọ ọwọ bayi.

Ogo! Ogo; Halleluyah!

Ogo! Ogo Halleluyah!

(Jesu Oluwa, bukun fun awọn aṣọ ilewọ wọnyi)

Ogo ni fun Ọlọrun! Bayi, ẹ jẹ ki a tẹ ori wa ba ni iṣẹju kan.

107 O dé ni akoko ti o yẹ arakunrin Ruddell. Wa si ibiyi ni iṣẹju kan. Arakunrin Ruddell, ọkan ninu awọn arakunrin alabaṣiṣẹpọ wa, nibiyi, ti agbarijọpọ awọn ijọ kekere ti a ni papọ, o jẹ ẹgbẹ ti o ni orișiriși awọn ọmọ ijọ, ẹlẹkọ-adamọ. Mo si ti gbọ nipa iduro akin ti Arakunrin Ruddell ti ni fun Ihinrere. Nitorina mo sọ eleyi, Arakunrin Ruddell, pe gbogbo ohun ti o wa ni oju ọna naa….. Ọlọrun ko ṣe ileri oju ọna ti o dan mọran, sugbọn O ti ṣe ileri ogun kan. Bẹẹni, sugbọn O ti ṣe ileri iṣẹgun. Ohun naa niyi.

Mo ranti nigbati Emi kọkọ mu iduro mi, iya ati baba mi paapa gbiyanju lati le mi jade kuro ni ile. Ṣe ẹ ri? Sugbọn o, akika! Mo ṣe iribọmi fun wọn ni orukọ Jesu Oluwa. Ireti kan ṣoṣo ti mo ni loni jẹ nitori iduro mi. Inu mi dun pe iwaasu inu Bibeli lati ọdọ oniwaasu atijọ naa ti o n gẹsin kiri titi ti o fi di akoko yi…… Bi o tilẹ jẹ wipe awọn eniyan ti mu u ti wọn si ti gé e kuro lara rẹ, wọn si ti mu ijọ ẹlẹkọ adamọ jade, wọn si ti fi ẹkọ-kẹkọ ati ohun gbogbo miran sinu rẹ, otitọ naa si tun gbilẹ si. Bẹẹni, o si tun n tẹsiwaju.

108 Ki Ọlọrun ko bukun fun olukuluku yin, a si ni ireti pe a o tun ri yin ni ẹekan si laipẹ. Titi ti o fi di igba naa, ṣe ẹyin yoo ṣe oore ẹyọkan yi fun mi nisisiyi ni ibiyi ati ni ibiti wọn ti n gbọ awọn ohùn ti a gba silẹ pẹlu, ẹyin ará. Gbadura pé Ọlọrun yoo fi sinu ọkan mi ohun ti mo padanu nibẹ ninu èrò-odi yẹn. O rọrun lati ni èrò-odi kan. Mo ṣe ifọrọwanilẹnuwo ni ọjọ kan pẹlu arakunrin mi, Arakunrin Way ti o joko nibiyi. Ti o joko nibiyi, o wa nibi. Ọkunrin daradara kan, sugbọn o mọ ero-odi yi ara rẹ kà, iru ero-odi miran. O ṣe ohun kanna. Arakunrin Way, o le ṣe eleyi pẹlu irọrun. Kan ni ohun kekere kan ni ọkan rẹ, tẹsiwaju lati maa ronu ni ọna yi… Pada lọ ki o si wo eleyi pẹlu Iwe-Mimọ, woo boya o jẹ otitọ tabi kii ṣe otitọ, lẹyin naa tẹsiwaju lati ibẹ lọ. Bẹẹni, maṣe padanu imọlara fun awọn eniyan naa. Ṣe ẹ ri? O gbọdọ ranti pe a ko da wọn pẹlu awọn èérún igi. Wọn jẹ ẹran ara ati ẹjẹ, eniyan ti o ni ẹjẹ, wọn si ni ọkan. Gbadura fun mi, gbogbo yin patapata, ti ẹyin ba fẹ. Ki Ọlọrun ko bukun fun yin nisisiyi.

A o tẹ ori wa ba, a o si bere ti Arakunrin Ruddell ba fẹ.

109 (A fi aye gba ọkunrin kan lati sọrọ) O dara, Arakunrin, (O sọ ala kan) Ogo ni fun Ọlọrun! Oniwaasu ni o jẹ. Ẹnikan le ma mọ. O si jẹ ọkan lara ẹgbẹ ti (Emi ko ni akoko ni owurọ yi) eleyi jẹ ọkan lara awọn ala wọnyi, ti o n sọ nipa mi pe mo lọ si ọna miran. Ṣe ẹ ri, mo n lọ si apa iwọ-oorun, mo n jade lọ si apa iwọ-oorun fun akoko ti o gbẹyin yi. Arakunrin J.T. Parnell.

110 Bayi, alejo lee wa ti yoo jẹ ohun iyalẹnu pe awọn eniyan n la ala, ti awọn alá-àlá. Rara, a ko fọwọ si orişirişi ala, sugbọn a gbagbọ pe Bibeli sọ wipe, “Yoo si ṣe ni opin ọjọ pe Emi yoo tu Ẹmi Mi jade si ori gbogbo eniyan, wọn yoo si sọtẹlẹ, wọn yoo si ri iran, wọn yoo si la awọn ala.” Niwọn igbati eleyi ba ṣi wa ninu Bibeli, o jẹ ojuṣe mi lati gba a gbọ, ati lati waasu rẹ. Ati nigbati awọn eniyan ba rọ ala, ti Ọlọrun ko ba ṣe itumọ rẹ, a maa fi silẹ. Ti o ba si jẹ ohun kan…… Ti ẹnikẹni ba fi ede tuntun sọrọ, o gbọdọ jẹ ohun kan fun ijọ, o si gbọdọ ṣẹlẹ, pẹlu. Ti ko ba ṣẹlẹ, o jẹ ẹmi eṣu kan ni. O gbọdọ wa si imuṣẹ, nitori itumọ fifi ede tuntun sọrọ, jẹ isọtẹlẹ. A mọ pe eleyi jẹ otitọ. Nitorina, a gbiyanju ni ibiyi lati gbe igbesi aye Bibeli ni ọna ti a fi kọni gẹlẹ. Maṣe mu ohunkohun kuro ninu rẹ tabi maṣe fi ohunkohun kun un, sugbọn kan fi I silẹ ni ọna ti a fi sí gẹlẹ. Ibukun ni fun Oluwa. Eleyi ran mi lọwọ, Arakunrin J.T lati gba eleyi gbọ….. Ọlọrun ko sọ fun mi pe jade lọ bayi ki o si gbabọde pẹlu ẹṣẹ. Sugbọn kan jade lọ, ki o si maa tẹsiwaju lati maa ṣe, ṣe ẹ ri.

111 Ẹ jẹ ki a gbadura bayi. (obinrin kan ninu apejọpọ pariwo sita) Ẹnikan daku. Ẹ jọwọ fun iṣẹju kan gbogbo yin ẹ fi ara balẹ.

Baba wa ọrun, jẹ ki aanu Rẹ sọkalẹ ki o si wo Arakunrin Way san, ni orukọ Jesu Kristi. Mo gbadura pe ki o pada wa. Mu u pada wa Oluwa, fun ni okun ati ilera-pipe.

Ran mi lọwọ Oluwa, ọkan rẹ bẹrẹ sii mi pada. Jesu Oluwa, Jẹ ki oore Rẹ ati aanu Rẹ wa pẹlu rẹ. O ti pari. Bi mo ti ṣe duro nibiyi ni ori pẹpẹ yi nibiti a ti waasu ọpọlọpọ isinku. Ni ibiti mo duro yi, nibiti a ti gbadura fun ọpọlọpọ awọn eniyan lati wa si ọdọ Kristi. Mo bẹrẹ silẹ oju rẹ ti pade, èémí rẹ si ti lọ. Ko si ohun miran ti a le ṣe ju pe ki a pe orukọ Jesu Kristi, eemi rẹ si bẹrẹ si ni pada bọ. Ẹ yin Oluwa logo! Gẹgẹ bi oniwaasu agbelebu, mo sọ eyi ni orukọ Jesu Kristi. Ṣe oun ko ha jẹ iyanu? O ni ikọlu ti ọkan, ṣe ẹ ri? Mo dupẹ pe o ṣẹlẹ nisisiyi, dipo ti yoo fi duro di igba ti a ba tuka. Ṣe ẹ ri oore-ọfẹ Ọlọrun? Ibukun ni fun Oluwa. Ẹ kan jẹ ki a tẹ ori wa ba.

112 Baba wa Ọrun, a dupẹ lọwọ Rẹ nisisiyi, fun ore Rẹ ati aanu Rẹ. Nigba gbogbo ni O maa n wa ni aarin wa. Fifun mi, Oluwa, ororo ninu atupa mi. Fun mi ni ọ̀pá Oluwa, ki emi ba a le na an sita, si ori awọn alaisan ati awọn ti a n pọn loju. Ki emi le fi si ita si ori…… Lati le mu itusilẹ wa fun awọn ti o jẹ alaini, ati idajọ fun awọn ti wọn ko gba a. Ṣe eyi, Baba. A dupẹ lọwọ Rẹ fun gbogbo ore Rẹ, ni orukọ Jesu Kristi Amin.

Arakunrin Ruddell……… ki Ọlọrun ko bukun fun ọ. Arakunrin.

MESSAGE hub online

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7